**NATIONAL OPEN UNIVERSITY OF NIGERIA (NOUN)**

# YOR 312: SÍSỌ ORÚKỌ NÍ YORÙBÁ
# (NAMING IN YORUBA)

**ADÉNÍYÌ ÀKÀNGBÉ**
***B.A. Hons (OAU), MCA, M.A., Ph.D., MPCS (Ibadan)***
**Department of Library, Archival and Information Studies**
**University of Ibadan**
**Ibadan, Nigeria**

**COURSE CODE:** YOR 312

**COURSE TITLE:** SÍSỌ ORÚKỌ NÍ YORÙBÁ (NAMING IN YORUBA)

**COURSE DESCRIPTION:**

This course introduces students to names and naming in Yoruba, the significance of Yoruba names, naming ceremony and rites, and name-oriented proverbs in Yoruba. The various categories of names include: Given names (Orúkọ Àbísọ), Traditional religion-oriented names (Orúkọ Ẹ̀sìn Ìbílẹ̀), Birth-oriented names (Orúkọ Àmútọ̀runwá), and *Àbíkú* names (Orúkọ Àbíkú). Other categories of names which the students are introduced to are: Praise names (Òrúkọ Oríkì), Appellative names (Orúkọ Àlàjẹ́), and Cognomens (Orúkọ Ìnagijẹ). Lineage poetry (Oríkì Orílẹ̀) and Challenges of Yoruba names (Ìpèníjà fún Orúkọ Yorùbá) conclude the course.

**COURSE WRITER:** Dr. Adéníyì Àkàngbé

**COURSE EDITOR:** Professor Ọládélé Orímóògùnjẹ́

**ÌFÁÁRÀ SÍ KỌ́Ọ̀SÌ YÌÍ**

Orúkọ ṣe pàtàkì sí ìran Yorùbá púpọ̀. Ipò ọ̀wọ̀ ni Yorùbá to orúkọ sí, wọn kò sì fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú un rárá. Gbogbo orúkọ tí ọmọ Yorùbá ń jẹ́ ni ó ní ìtumọ̀ kíkún, ó ní ìdí tí wọ́n fi ń jẹ́ ẹ, ojúṣe kówá sì ni láti tọ́jú orúkọ ara rẹ̀ àti ti ìdílé rẹ̀.

Àkọlé gbóòrò kọ́ọ̀sì yìí ni "Orúkọ Sísọ ní Yorùbá". A pín àkọlé yìí sí ẹlẹ́kajẹ̀ka lọ́nà tí yóò fi rọrùn fún àwon akẹ́kọ̀ọ́ láti mọ̀. Odidi Módù mẹ́ta ni a pín in sí, Módù àkọ́kọ́ ní ìpín méjì nígbà tí Módù kejì àti ìkẹta ní ìpín mẹ́rin mẹ́rin. Àwọn àkóónú Módù àkọ́kọ́ ni: Pàtàkì Orúkọ́ ní Ilẹ̀ Yorùbá, àti Àṣà Ìsọmọlórúkọ. Módù yìí ló jẹ́ ìfáárà sí àwọn ìsọ̀rí orúkọ tí a sọ̀rọ̀ bá nínú Módù méjèèjì yòókù.

Módù kejì ni a pe àkòrí rẹ̀ ní "Ìsọ̀rí Orúkọ Yorùbá 1". Àwọn àkọlé tí ó wà lábẹ́ rẹ̀ ni: Orúkọ Àbísọ, Orúkọ Ẹ̀sìn Ìbílẹ̀, Orúkọ Àmútọ̀runwá, àti Orúkọ Àbíkú. Módù kẹta tí a pe àkòrí rẹ̀ ní "Ìsọ̀rí Orúkọ Yorùbá 2" tí a pín sí ọ̀nà mẹ́rin tún ṣe àlàyé sí i lórí àwọn ìsọ̀rí tí orúkọ Yorùbá pín sí. Àwọn àkóónú Módù kẹta yìí ni: Òrúkọ Oríkì, Orúkọ Àlàjẹ́, àti Orúkọ Ìnagijẹ. Ìpèníjà fún Orúkọ Yorùbá ni ó pẹ̀kun àwọn àkóónú yìí.

Ní òpin ẹ̀kọ́ kọ̀ọ̀kan ni a to àwọn ìwé ìtọ́kasí fún akẹ́kọ̀ọ́ láti ṣe àmúlò fún àníkún ìmọ̀.

**ÀFOJÚSÙN KỌ́Ọ̀SI YÌÍ**

Orúkọ kò ṣe é fi ọwọ́ rọ́ sẹ́yìn nínú èdè àti àṣà Yorùbá. Àbùdá pàtàkì ni orúkọ jẹ́ fún olórúkọ, orúkọ sì jẹ́ atọ́ka tí ó ń sọ ohun púpọ̀ nípa olórúkọ. Kò sí orúkọ kan tí Yorùbá sọ tí kò ní ìdí ìbáà ṣe orúkọ ènìyàn, ìlú, ohun abẹ̀mí mìíràn tàbí ohun tí kò ní ẹ̀mí. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ nǹkan ni Yorùbá máa ń wò, pàápàá, kí wọ́n tó sọ ọmọ wọn ní orúko. Kíkọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ ní ìṣepàtàkì orúkọ sí ìran Yorùbá àti onírúurú orúkọ tí wọn ń jẹ́ ni ó pilẹ̀ jẹ́ àfojúsùn kọ́ọ̀sì yìí.

A tẹpẹlẹ mọ́ àṣà ìsọmọlórúkọ ní ilẹ̀ Yorùbá. Ayẹyẹ tí Yorùbá kà sí gidi ni ìsọmọlórúkọ jẹ́, ó sì ní àwọn orò tí wọ́n máa ń tẹ̀lé. Bí orúkọ ti ṣe bàbàrà sí wọn tó ló mú kí àwọn òwe ajẹmórúkọ máa hàn nínú ọ̀rọ̀ àti ìwòye wọn.

A tún fúnka mọ́ ọn pé orúkọ Yorùbá pín sí onírúurú ọ̀nà. Èyí ni a fi hàn nípa ìdánilẹ́kọ̀ọ́ lórí àwọn ìsọ̀rí orúkọ bí i orúkọ àbísọ, orúkọ ẹ̀sìn ìbílẹ̀, orúkọ àmútọ̀runwá, abbl. A ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn onírúurú ìsọ̀rí orúkọ Yorùbá kí àlàyé wa lórí orúkọ lè kún, kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ sì lè mọ orísun àwọn orúkọ ọmọ káàárọ̀ oòjíire.

**OJÚṢE AKẸ́KỌ̀Ọ́**

Fún àṣeyọrí olùkọ́ àti akẹ́kọ̀ọ́ nínú kọ̀ọ̀sì yìí, kálukú wọn ni ó ní iṣẹ́ láti ṣe. Bí olùkọ́ ṣe ní iṣẹ́ tirẹ̀, bẹ́ẹ̀ náà ni akẹ́kọ̀ọ́ náà ní ojúṣe tirẹ̀ láti mú èròńgbà kọ́ọ̀sì yìí wá sí ìmúṣẹ. Iṣẹ́ olùkọ́ ni láti fi ara balẹ̀ kọ́ àwọn akẹ́kọ̀ọ́ rẹ̀. Iṣẹ́ akẹ́kọ̀ọ́ sì ni láti farabalẹ̀ gba ìtọ́ni àti ìtọ́sọ́nà olùkọ́, èyí tí yóò mú kí ìmọ̀ wọn gbóòrò sí i nípa orúkọ ìran Yorùbá.

Ó ṣe pàtàkì fún akẹ́kọ̀ọ́ láti ka ojú ìwé kọ̀ọ̀kan tí ó wà nínú àpilẹ̀kọ̀ yìí dáradára kí ó sì tún ṣe àkàtúnkà rẹ̀. Lẹ́yìn tí ó bá ti kà á yékéyéké tán, àkẹ́kọ̀ọ́ gbọ́dọ̀ dáhùn àwọn ìbéèrè tí ó wà fún ìgbéléwọ̀n nínú àpilẹ̀kọ yìí. Èyí nìkan kọ́, ojúṣe akẹ́kọ̀ọ́ ni láti ṣe àwọn iṣẹ́ àmúrelé rẹ̀ gbogbo tí olùkọ́ bá fún un, kí ó sì dá a padà fún olùkọ́ tí yóò ṣe ìgbéléwọ̀n rẹ̀. Bí ó bá ṣe èyí, yóò lè mọ bí ó ṣe kún ojú ìwọ̀n sí àti ibi tí ó tún kù sí. Ó wúlò fún akẹ́kọ̀ọ́ láti bèèrè àwọn nǹkan tí kò yé e lọ́wọ́ olùkọ́ rẹ̀ lásìkò tí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ bá ń lọ lọ́wọ́. Ìrànlọ́wọ́ ń lá ni èyí yóò jẹ́ fún un.

Láìṣe àní àní, ìmọ̀ tí akẹ́kọ̀ọ́ bá ní lórí orúkọ sísọ ní ilẹ̀ Yorùbá yóò wúlò fún un láti ṣe àṣeyege nínú ìdánwò rẹ̀ ní òpin sáà èkọ́. Yàtọ̀ sí èyí, akẹ́kọ̀ọ́ yóò tún ní àǹfààní láti lo ìmọ̀ rẹ̀ nínú kọ́ọ̀sì yìí láwùjọ. Èyí yòó sì fi í hàn bí ẹni tí ó mọ ìṣe àti àṣà Yorùbá.

**ÌGBÉLÉWỌ̀N AKẸ́KỌ̀Ọ́**

Ìgbéléwọ̀n wà fún akẹ́kọ̀ọ́ bí kọ́ọ̀sì yìí bá ti ń tẹ̀síwájú àti ní òpin kọ́ọ̀sì yìí. Ìgbéléwọ̀n àkọ́kọ́ ni iṣẹ́ ṣíṣe tí olùkọ́ yóò fi ọwọ́ sí, ìkejì ni ìdánwò alákọsílẹ̀. Èyí dá lórí iṣẹ́ àmúṣe tí àwọn akẹ́kọ̀ yóò dájọ fún olùkọ́ láti fọwọ́ sí láàrin àsìkò tí ó bá fi sílẹ̀ fún àdápadà. Iṣẹ́ àmúṣe jẹ́ ìdá ọgbọ̀n nínú ọgọ́rùn-ún. A ní ìrètí pé ìmọ̀ tí akẹ́kọ̀ọ́ bá gbà nínú ẹ̀kọ́ yìí yóò wúlò fún iṣẹ́ àmúṣe àti ìdánwò fún àṣeyege.

**ÌGBÉLÉWỌ̀N TÍ OLÙKỌ́ YÓÒ MÁÀKÌ**

Iṣẹ́ ṣíṣe wà ní òpin ìpín kọ̀ọ̀kan. À ń fọkàn sí i pé akẹ́kọ̀ọ́ yóò wá ìdáhùn sí gbogbo ìbéèrè tó wà níbẹ̀. Gbogbo àwọn iṣẹ́ ṣíṣe yìí ni a ó yẹ̀wò tí máàkì yóò si wà fún mẹ́ta tó bá dára jù. Yóò jẹ́ ẹyọ kan ní Módù kan. Módù Kìíní dá lórí Orúkọ àti Ìsọmọlórúkọ ní Ilẹ̀ Yorùbá, Ìkejì dá lórí Ìsọ̀rí Orúkọ Yorùbá 1, ìkẹta náà sì dá lórí Ìsọ̀rí Orúkọ Yorùbá 2.

Iṣẹ́ ṣíṣe àti ìgbéléwọ̀n yìí ni a ó máa fi sọwọ́ papọ̀ sí olùkọ́ ṣaájú ọjọ́ tí a bá dá. Bí ìdí pàtàkì bá wà láti má ṣe dá iṣẹ́ náà padà kí ọjọ́ yìí tó pé, o ní láti fi tó olùkọ́ létí ẹni tí ó le pinnu láti sún ọjọ́ náà síwájú. Ìdí pàtakì ni ó lè mú kí olùkọ́ ṣe bẹ́ẹ̀.

**ÌDÁNWÒ ÀṢEKÁGBÁ ÀTI ÒṢÙNWỌ̀N**

Èyí ni Ìdánwò tí o ó jókòó ṣe lẹ́yìn tí ìdánilékọ̀ọ́ bá ti parí. Àwọn aláṣẹ ilé-ẹ̀kọ́ ni yóò kéde ọjọ́ àti àsìkò àti ibi tí ìdánwò yóò ti wáyé. Má ṣe gbàgbe pé ìdá àádọ́rin (70%) ni ìdánwò yìí kó nínú ọgọ́rùn-ún

**ÌLÀNÀ MÁÀKÌ GBÍGBÀ**

Àtẹ ìsàlẹ̀ yìí ṣe àfihàn bí máàkì gbígbà yóò ṣe wáyé.

| **Ìgbéléwọ̀n** | **Máàkì** |
|---|---|
| Iṣẹ́-ṣíṣe Módù 1-3 mẹ́ta tí ó dára jù ni a ó ṣe àkọsílẹ̀ máàkì rẹ̀ | Ọgbọ̀n (30%) |
| Ìdánwò Àṣekágbá | Àádọ́rin (70%) |
| Àpapọ̀ | Ọgọ́rùn-ún (100%) |

**AKÓÓNÚ KỌ́Ọ̀SÌ**

| | |
|---|---|
| **MÓDÙ KÌÍNÍ:** | **Orúkọ àti Ìsọmọlórúkọ ní Ilẹ̀ Yorùbá** |
| Ìpín Kìíní: | Pàtàkì Orúkọ́ ní Ilẹ̀ Yorùbá |
| Ìpín Kejì: | Àṣà Ìsọmọlórúkọ |

| | |
|---|---|
| **MÓDÙ KEJÌ:** | **Ìsọ̀rí Orúkọ Yorùbá 1** |
| Ìpín Kìíní: | Orúkọ Àbísọ |
| Ìpín Kejì: | Orúkọ Ẹ̀sìn Ìbílẹ̀ |
| Ìpín Kẹta: | Orúkọ Àmútọ̀runwá |
| Ìpín Kẹrin: | Orúkọ Àbíkú |

| | |
|---|---|
| **MÓDÙ KẸTA:** | **Ìsọ̀rí Orúkọ Yorùbá 2** |
| Ìpín Kìíní: | Òrúkọ Oríkì |
| Ìpín Kejì: | Orúkọ Àlàjẹ́ |
| Ìpín Kẹta: | Orúkọ Ìnagijẹ |
| Ìpín Kẹrin: | Ìpèníjà fún Orúkọ Yorùbá |

**Commented [OO1]:** Kò yẹ kí oríkì orílẹ̀ wà nínú Kọ́ọ̀sì yìí. Má pín ìsọ̀rí yìí sí méjì, kí àlàyé má sì pọ̀ lórí wọn, kí o má bàá dá akẹ́kọ̀ọ́ lágara.

**MÓDÙ KÌÍNÍ: Pàtàkì Orúkọ àti Ìsọmọlórúkọ ní Ilẹ̀ Yorùbá**

**Ìpín Kìíní: Pàtàkì Orúkọ́ ní Ilẹ̀ Yorùbá**

**Àkòónú**

**1.0 Ìfáárà**

Orúkọ ṣe pàtàkì púpọ̀ ní ilé ayé. Ohun gbogbo ni ó ní orúkọ yálà ohun abẹ̀mí tàbí aláìlẹ́mìí. Ìran Yorùbá ka orúkọ sí púpọ̀. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń ronú jinlẹ̀ kí wọ́n tó sọ ọmọ lórúkọ. Yorùbá kì í kùgbù fún ọmọ wọn ní orúkọ. Èyí ló fi ìdí òwe wọn múlẹ̀ pé, ilé là á wò kí á tó sọ ọmọ ní orúkọ.

**2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn**

Àfojúsùn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni láti jẹ́ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mọ:

- bí orúkọ ti ṣe pàtàkì sí ìran Yorùbá tó.
- bí wọ́n ṣe máa ń ronú jinlẹ̀ sí kí wọ́n tó sọ ọmọ ní orúkọ.
- bí wọn ṣe máa ń sapá láti dáàbò bo orúkọ wọn.

**3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú**

1. Oríkì wo ni o lè fún orúkọ?
2. Ǹ jẹ́ orúkọ ṣe pàtàkì sí Yorùbá bí?
3. Sọ àǹfààní mẹ́ta tí orúkọ ní láwùjọ Yorùbá.

**4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

**4.1 Kín ni Orúkọ?**

Orúkọ ni ìtọ́kasí tàbí àmì tí a fi sọrí ènìyàn fún ìdámọ̀. Ìtọ́kasí ni orúkọ jẹ́ fún ènìyàn, ó sì wà láti ya ẹnìkan sọ́tọ̀ sí ẹnìkejì ni. Láti ipasẹ̀ onírúurú àkíyèsí ni Yorùbá ti máa ń pinnu orúkọ fún ọmọ. Àkíyèsí yìí lè jẹ́ ohun tí ó ṣẹlẹ̀ nígbà tí a bí ìkókó, ibi ti a bí i sí, ohun tí ó ń ṣẹlẹ̀ nínú ìdílé ní lọ́ọ̀lọ́ ìgbà tí a bí i, ipò tí ilé tàbí ìlú wà lásìkò tí a bí i, bí ìwásáyé ọmọ náà ti rí, àti onírúurú àkíyèsí bẹ́ẹ̀. Ìdí nìyí tí Yorùbá fi máa ń pa òwe pé: orúkọ ń roni, oríkì

ń ro ènìyàn. Bẹ́ẹ̀ ni. Orúkọ tí ọmọ bá ń jẹ́ a máa ṣe atọ́kùn ìwà rẹ̀. Ní kúkúrú, a lè sọ gẹ́gẹ́ bí òwe Yorùbá pé: Orúkọ ọmọ ni ìjánu ọmọ.

## 4.2 Pàtàkì Orúkọ

Yorùbá ka orúkọ sí bàbàrà púpọ̀. Fún ìdí èyi¸wọn a máa farabalẹ̀, wọn a sì máa ronú jinlẹ̀ kí wọ́n tó fún ọmọ ní orúkọ. Ìdí àkọ́kọ́ tí orúkọ fi ṣe pàtàkì ni pé ìdánimọ̀ ni ó jẹ́. Èrèdí ohun gbogbo tí a sọ ní orúkọ ni pé kí á lè dá wọn mọ̀. Ènìyàn nìkan kọ́ ni ó ní orúkọ. Gbogbo ohun tí ó ń mí àti èyí tí kò mí ni ó ní orúkọ tirẹ̀. Kò sí ohun tí a fi ń ya ẹnìkan sọ́tọ̀ sí ẹlòmíràn ju orúkọ lọ. Bí a bá kó ọ̀pọ̀ ènìyàn jọ, orúkọ ní ó jẹ́ àmì ìdáyàtọ̀ tí ó hànde jù.

Orúkọ tún ṣe pàtàkì nítorí pé ó wà fún ìtọ́kasí. Gẹ́gẹ́ bí àmì fún ìdáyàtọ̀, orúkọ Yorùbá a máa ṣe ìtọ́kasí onírúurú nǹkan. Orúkọ a máa tọ́ka sí ìdílé, iṣẹ́, ẹ̀sìn, ìlú, ìwà, abbl. Bí àpẹẹrẹ, orúkọ “Adé” bí i Adéyẹmí, Adéyẹrí, Adéníyì, Adéríyè, Adéọba, Adékúnlé, Adégbóyèga, Adéfúnnkẹ́, Adébọ̀lá, Adébóyin, Adéníkẹ̀ẹ́, abbl ń tọ́ka sí ìdílé ọba aládé. Gẹ́gẹ́ bẹ́ẹ̀ ni orúkọ tí ó bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú “Oyè” bí i Oyèníkẹ̀ẹ́, Oyèmọ́milára, Oyèwùmí, Oyèbọ́ádé, Oyèdèmí, Ajíbóyè, Oyèéníran, abbl pẹ̀lú ń tọ́ka sí ìdílé Oyè.

Orúkọ bí i Ọ̀jẹ́dàpọ̀, Ọjẹ́làdé, Ọ̀jẹ́níkẹ̀ẹ́, Ọ̀jẹ̀labí, Abọ́jẹ̀dé, Eégúnlétí, Eégúnbíyìí, Eégúnjọbí, abbl. jẹ́ orúkọ ẹ̀sìn tí ó ń fi ìdílé Eléégún hàn. Bẹ́ẹ̀ náà ni orúkọ Ifá, Awo, Ògún, Ọya, Ewé, Ọ̀ṣún, abbl ń ṣe àfihàn ẹ̀sìn tí ìdílé kan ń sìn.

Yorùbá tẹpẹlẹ mọ́ orúkọ rere púpọ̀. Wọn a máa ṣe ohun gbogbo tí ó tọ́ láti mú kí orúkọ wọn dára. ìwà ni ọ̀pákùtẹ̀lẹ̀ fún dídáàbò bo orúkọ ẹni. Nítorí èyí, wọn kì í jẹ́ kí owó, ipò tàbí agbára pa orúkọ wọn lára rárá. Àti olówó àti mẹ̀kúnnù ló máa ń sára kí orúkọ wọn má bàjẹ́. Èyí ló mú wọn máa pa òwe pé 'Orúkọ rere sàn ju wúrà lọ''

Atọ́kùn ni orúkọ jẹ́ fún ọmọ. Orúkọ tí a bá sọ ọmọ máa ń ní ipa lórí ayé ọmọ. Èyí mú kí Yorùbá ka orúkọ sí bàbàrà púpọ̀.

## 5.0 Ìsọníṣókí

A ti ṣe àlàyé ohun tí orúkọ jẹ́ ní ilẹ̀ Yorùbá. A rí orúkọ gẹ́gẹ́ bí àmì fún ìtọ́kasí, ìdánimọ̀ àti ìyàsọ́tọ̀. Orúkọ jẹ́ ohun bàbàrà tí Yorùbá kì í fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú rárá. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ẹ̀wẹ̀, a tún ṣe àlàyé bí orúkọ ti ṣe pàtàkì sí.

## 6.0 Iṣẹ́ Síṣe

i. Ṣàlàyé ohun tí orúkọ jẹ́ sí àwọn Yorùbá.

ii. Ǹ jẹ́ orúkọ ṣe pàtàkì sí Yorùbá bí?

iii. Sọ àǹfààní mẹ́ta tí orúkọ ní láwùjọ Yorùbá.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Adéoyè, C.L. (1979). *Àṣà àti Ìṣe Yorùba.* Ìbàdàn: Oxford University Press.

Dáramọ́lá, O. & Jẹ́jẹ́, A. (1967). *Àṣà Àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn: Oníbọnòjé Press Limited.

Ládélé, T.A.A. *et al* (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ìbàdàn: Gavima Press.

**Ìpín Kejì: Àṣà Ìsọmọlórúkọ**

**Àkòónú**

**1.0 Ìfáárà**

Ọ̀kan pàtàkì lára àṣà Yorùbá ni ìsọmọlórúkọ jẹ́. Gbogbo àwùjọ Yorùbá ni ó sì káràmásìkí àṣà yìí. Yorùbá ka orúkọ sí bàbàrà, torí náà wọn kì í fi ọwọ́ yẹpẹrẹ mú orúkọ. Ilé ni a máa ń wò kí á tó sọ ọmọ ní orúkọ ní ilẹ̀ Yorùbá, wọn kì í ṣàdéédé, sọ ọmọ ní orúkọ kan ṣá. Nítorí ìdí èyí, wọn a máa ṣe àkíyèsí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ tí ó ṣẹ̀ ní lọ́ọ̀lọ̀ ìgbà tí a bí ọmọ kan kí wọ́n tó ṣọ ọ́ ní orúkọ.

**2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn**

Àfojúsùn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí ni láti jẹ́ kí àwọn akẹ́kọ̀ọ́ mọ:

- ìdí tí a fi ń sọ ọmọ lórúkọ
- ètò ìsọmọlórúkọ ní ilẹ̀ Yorùbá
- àwọn ohun èlò fún ìsọmọlórúkọ
- ohun tí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ohun èlò wọ̀nyí dúró fún.

**3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú**

1. Kín ni ìdí tí Yorùbá fi ń sọ ọmọ lórúkọ?
2. Báwo ni a ṣe ń sọ ọmọ lórúkọ ní ayé àtijọ́?
3. Kín ni àwọn ohun èlò fún ìsọmọlórúkọ
4. Kín ni ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ohun èlò wọ̀nyí dúró fún?
5. Àwọn àyípadà tí ó dé bá àṣà ìsọmọlórúkọ lóde òní

**4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

**4. 1 Ìdí tí a fi ń sọ ọmọ ní orúkọ**

Ìdí pàtàkì tí a fi ń sọ ọmọ ní orúkọ ní ilẹ̀ Yorùbá ni ìdánimọ̀. Orúkọ ni a fi ń sàmì sí ọmọ kọ̀ọ̀kan lára. Nítorí náà, ajúwe ni orúkọ jẹ́ fún ẹ̀dá kọ̀ọ̀kan. Bàbàrà ni orúkọ jẹ́ fún ìran Yorùbá. Fún ìdí èyí, tara tẹ̀mí ni Yorùbá fi máa ń gbáradì fún ìsọmọlórúkọ.

**4.2 Ètò ìsọmọlórúkọ ní ayé àtijọ́**

**Ìkókó:** Ọmọ ti a bá ṣẹ̀ṣẹ̀ bí ni a ń pè ní ìkókó. Títí tí a ó fi sọ ọmọ lórúkọ, ìkókó tàbí túńfúlù ni a máa ń pe ọmọ jòjòló. Ṣáájú ọjọ́ ìsọmọlórúkọ, wọn a tún máa pe ọmọ tuntun ní àlejò. Bí ó bá jẹ́ ọmọ tí ó mú orúkọ wá láti ọ̀run ni, wọn a máa pè é ní irú orúkọ àmútọ̀runwá bẹ́ẹ̀. Àpẹẹrẹ orúkọ bẹ́ẹ̀ ni Táíwò, Kẹ́hìndé, Ìdòwú, Àjàyí, abbl. Bía bá bímọ sáyé tán, àdúrà Yorùbá ni pé kí ọmọ dúró gba orúkọ. Nínú ètò ìsọmọlórúkọ ni a ti máa ń sọ ọmọ lórúkọ tí yóò máa jẹ́ títí ayé.

**Wíwà ní yàrá:** Inú yàrá tí a ti fi ìyá ọmọ àti ọmọ rẹ̀ sí náà ni yóò wà títí di ọjọ́ ìsọmọlórúkọ. Ìgbà tí ìyá ọmọ bá fẹ́ wẹ̀ tí yóò sì ba ara rẹ̀ pẹ̀lú omi gbígbóná nìkan ló tó lè jáde nínú yàrá yìí. Àwo oúnjẹ tó jẹ kò ní jẹ́ kíkó, a ò sì ní gbá yàrá tí ìyá ọmọ àti ọmọ tuntun wà yìí títí di ọjọ́ ìsọmọlórúkọ. A gbàgbọ́ pé ara ọmọ tuntun ni àwọn nǹkan wọ̀nyí, bí a bá sì gbé wọn jáde, a ti gbé ọmọ tuntun jáde náà nìyẹn.

**Èèwọ̀:** Èèwọ ni àwọn nǹkan tí ìdílé kan ní láti ṣe tàbí tí wọn kò gbọdọ̀ ṣe bí wọ́n bá bímọ. Ó ní èèwọ̀ ìdílé tí ìyá ìkókó gbọ́dọ̀ wọ̀ láti ọjọ́ tí ó bá ti bímọ títí di ọjọ́ ìsọmọlórúkọ. Èèwọ ni àwọn nǹkan tí ìdílé kan ní láti ṣe tàbí tí wọn kò gbọdọ̀ ṣe bí wọ́n bá bímọ. Ìdílé mìíràn kì í jẹ ẹran, iyọ̀ àti epo gẹ́gẹ́ bíi èèwọ̀ ìdílé wọn. Bí àpẹẹrẹ, ẹyẹ ẹ̀gà ni àwọn ìran Olúòjé kì í jẹ. Yálà ìyá ìkókó ni tàbí bí ìran wọn bá dàgbà, èèwọ̀ ni ẹyẹ ẹ̀gà jẹ́ fún wọn. Orí ẹní àkújá, ẹní tó ti gbó, ní ìyá ìkókó á máa sùn ní ìdílé mìíràn títí yóò fi ṣe ìsọmọlórúkọ. Ẹ̀wẹ̀, aláǹgbá ni àwọn ìdílé mìíràn máa ń jẹ kí wọ́n tó sọ ọmọ wọn lórúkọ.

**Àkọsẹ̀jayé/Ẹsẹ̀ǹtayé:** Wíwo ẹsẹ̀ǹtayé tàbí àkọsẹ̀jáyé ọmọ tuntun ni orò mìíràn tí ó pọn dandan fún ìkókó tàbí túńfúlù. Àwọn àgbà inú ìdílé tí a ti bímọ tuntun yìí á ti lọ wo àkọsẹ̀jáyé tàbí ẹsẹ̀ǹtáyé ọmọ tuntun yìí kí ó tó di ọjọ́ ìsọmọlórúkọ. Wọ́n á lọ béèrè lọ́wọ́ Ifá

ẹsẹ̀ ẹni tí ọmọ náà tọ̀ wáyé; irú orí tí ó yàn wáyé, òrìṣà tí yóò máa sìn, iṣẹ́ tí yóò ṣe bí ó bá dàgbà, abbl. Gbogbo ohun tí ó ní ṣe pẹ̀lú àyànmọ́ rẹ̀ ni àkọsẹ̀jayé rẹ̀ yóò fi hàn ní kíkún. Bí ó bá jẹ́ pé ẹsẹ̀ rere ni ó mú wáyé, èyí ni pé bí ó bá jẹ́ pé oríire ló mú wáyé, wọ́n á ṣe ètùtù kí oríire náà ó má bàjẹ́, bí ó bá sì jẹ́ pé ẹsẹ̀ búburú ló tọ̀ wáyé tí ó mú orí burúkú wáyé, wọ́n á tún ṣe ètùtù kí Ẹlẹ́rìí-Ìpín ó lè bá wọn yí ibi padà sí rere.

**Gbígbé ọmọ kọjá lábẹ́ òrùlé:** Orò mìíràn tí Yorùbá tún máa ń ṣe ní ọjọ́ ìkómọ ni sísáré gbé ọmọ kọjá lábẹ́ omi tí a dà sí orí òrùlé ilé. Wọ́n á bu omi sórí òrùlé, ìyá ọmọ á sì gbé ọmọ yìí kọjá lábẹ́ omi náà kí ó tó sàn padà sílẹ̀. Ìyá ọmọ yóò ríi pé omi orí òrùlé yìí dà sí ọmọ náà lára kí ó tó sàn padà sílẹ̀. Bí ọmọ yìí bá ké tàbí tí ó gbọ̀n nígbà tí omi dà sí i lára a jẹ́ pé ọmọ náà máa ya ojo nìyẹn ṣùgbọ́n bí ó bá ṣojú fúrú tí kò ké tòò tàbi kí ó gbọ̀n rìrì, ó túmọ̀ sí pé akin ọmọ ni yóò yà nìyẹn. Èrèdí orò yìí ni láti fi ṣàdúrà fún ọmọ náa pé bí ó bá dàgbà, tí ó ń jàde nínú òjò àti ẹ̀ẹ̀rùn láti wá ìjẹ lọ fún ẹbí rẹ̀, kì yóò ní ìpalára kankan.

**Fífún ọmọ lórúkọ:** Ọjọ́ kẹ́sàn-án la máa ń fún ọmọ ọkùnrin lórúkọ ní ilẹ̀ Yorùbá, ọjọ́ keje ni ti àwọn ọmọ obìnrin nígbà tí ti àwọn ìbejì jẹ́ ọjọ kẹ́jọ. Ilé baálé ẹbí ni ìsọmọlórúkọ ti máa ń wáyé, àárọ̀ kùtùkùtù sì ni a máa ń ṣe ayẹyẹ ìsọmọlórúkọ. Baálé ilé, ìyáálé ilé tàbí ẹni tí wọ́n bá yàn láàrin ẹbí ni yóò gbé ìkókó lọ́wọ́ tí yóò sọ ìtàn ìdílé ọmọ náà ní ṣókí, yóò sì tún sọ àkíyèsí wọn nípa ọmọ yìí láti ìgbà tí wọ́n ti lóyún rẹ̀ títí di àsìkò ìsọmọlórúkọ.

Baálé ilé ni yóò kọ́kọ́ fún ọmọ lórúkọ tí yóò sì fi gbogbo àwọn èròjà tí a kà sílẹ̀ wọ̀nyí ṣe àdúrà fún un, lẹ́yìn náà ni yóò kan ìyáálé ilé kí ó to wá kan àwọn òbí ọmọ àti mọ̀lẹ́bí yòókù. Ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn wọnyí ni yóò máa fún ọmọ ní orúkọ tí ó wù wọ́n, ìdí nìyí tí orúkọ ọmọ ṣe máa ń pọ̀. Wọ́n á ti bu omi tútù sínú igbá kan, inú omi yìí sì ni wọ́n a máa sọ owó sí kí wọ́n tó fún ọmọ lórúkọ. Owó ẹyọ ni wọ́n ń ná láyé àtijọ́, ìdí nìyí tí ó fi lè gbé inú omi láìdíbàjẹ́. Ìyá ọmọ ni yóò bá ọmọ kó owó yìí pamọ́. Lẹ́yìn gbogbo ètò yìí, àwẹ̀jẹwẹ̀mu ni ó kù, wọn yóò kó jíjẹ àti mímu jáde, àwọn alábàáṣe yóò sì bá àwọn aláyọ̀ dáwọ̀ọ́ ìdùnnú kí kálùkù wọn tó padà sí ilé tàbí ẹnu iṣẹ́ wọn.

**4.3 Àwọn ohun tí a fi ń ṣọ ọmọ lórúkọ**

Àwọn ohun pàtàkì tí Yorùbá máa ń lò fún ìsọmọlórúkọ ni omi, iyọ̀, epo pupa, ẹja, ataare, irú, orógbó, obì, oyin, ìrèké, ààdùn, ọtí, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn nǹkan wọ̀nyí ló ní ìtumọ̀ nínú àṣà ìsọmọlórúkọ láàrin àwọn Yorùbá. A máa ń fi àwọn nǹkan wọ̀nyí ṣe àdúrà fún ìkókó lọ́kọ̀ọ̀kan ni.

**4.4 Ohun tí àwọn ohun èlò wọ̀nyi dúró fún**

Ẹ jẹ́ kí á wo àwọn ohun èlò wọ̀nyí ní ọ̀kọ̀ọ̀kan kí á si ṣe àlàyé ohun tí wọ́n dúró fún. **Omi** ṣe pàtàkì nílé ayé, ìdí nìyí tí Yorùbá fi máa ń sọ pé 'a kì í bá omí ṣe ọ̀tá'. Omi ni a bù wẹ̀, omi ni a bù mu, omi sì ni a bù bọ́jú. Ojoojúmọ́ ni a máa ń lo omi. Àdúrà tí a ó fi omi gbà fún ọmọ tuntun jòjòló ni pé kò ní ní ọ̀tá, àti pé ọ̀rẹ́ ni gbogbo ayé yóò máa báa ṣe bí gbogbo ayé ṣe ń bá omi ṣe ọ̀rẹ́.

**Ẹja**: Tútù ni a máa ń bá ilé ẹja, ilé ẹja kì í gbóná; àdúrà tí à ń fi èyí gbà fún ọmọ ni pé ayé rẹ̀ yóò tutù àti pé kò ní rí ìdààmú nílé ayé rẹ̀. A máa ń fi ẹja gbígbẹ ṣe àdúrà pé orí ni ẹja fi ń la ibú, ọmọ náà yóò fi orí rẹ̀ la gbogbo ìsòro ayé rẹ̀ já yóò sì borí gbogbo wọn.

**Iyọ̀:** Dandan ni iyọ̀ jẹ́ ní àwùjọ oúnjẹ, a sì máa mú oúnjẹ dùn. Yàtọ̀ sí èyí, iyọ̀ kì í jẹ́ kí nǹkan tètè díbàjẹ́. Àdúrà tí à ń fi iyọ̀ gbà fún ọmọ tuntun ẹ̀jẹ̀ ọ̀run ni pé iyọ̀ àti adùn ayé ni yóò jẹ́. Yàtọ̀ fún èyí, bí iyọ̀ ṣe máa ń jẹ́ kí nǹkan tọ́jọ́, bẹ́ẹ̀ ni òun náà yóò tọ́jọ́, kò sì ní díbàjẹ́ pẹ̀lú.

**Oyin, Ààdùn àti Ìrèké: Adùn ni** oyin dúró fún torí pé dídùn dídùn ni à ń bá ilé oyin àti pé ẹnìkan kì í fi oyin sẹ́nu kó ba ojú jẹ́. Àdúrà tí à ń fi oyin ṣe fún ọmọ tuntun ni pé ayé rẹ yóò lóyin, ọmọ aráyé kò sì ní bínú rẹ. Bákan náà ni tí ààdùn àti ìrèké. Ọ̀rọ̀ bí adùn bí i adùn kì í tán lọ́rọ̀ ìrèké àti ààdùn náà dúró fún. Àdúrà ìgbéayé tí ó kún fún adùn àti ayọ̀ náà ni à ń fi nǹkan méjèèjì yìí gbà.

**Epo pupa:** Àdúrà tí à ń fi epo pupa ṣe ni pé kí ọmọ tuntun náà fi ìrọ̀rùn, ìdẹ̀ra àti ìtura gbé ilé ayé rẹ̀. A tún ń gbà á ní àdúrà pé ọmọ náà kò ní rí ìpọ́njú láyé.

**Atare:** Àdúrà ìsọdipúpọ̀ ni a máa ń fi ataare ṣe pé ọmọ náà yóò dirún yóò sì digba. Yóò lówó lọ́wọ́, yóò bímọlémọ, yóò sì pọ̀ ní ọrọ̀. A tún ń fi ataare ṣe àdúrà ìṣọ̀kan pé bí ọmọ ataare ṣe dì papọ̀ sójú kan ní odidi náà ni ọmọ yìí yóò dúró fún ìsọ̀kan yóò sì jẹ́ okùnfà ìṣọ̀kan láàrin ìdílé rẹ̀.

**Ọtí** ṣe pàtàkì púpọ̀ láwùjọ. Yorùbá á ní 'ẹni ọtí kì í tí'. Àdúrà tí à ń fi ọtí ṣe fún ọmọ tuntun ni pé ayé rẹ̀ kò níí tí bẹ́ẹ̀ ni kò sì ní tẹ́ láwùjọ pẹ̀lú.

**Orógbó:** Igi orógbó a máà pẹ́ láyé kí ó tó kú, àdúrà ni pé ọmọ náà yóò dàgbà, yóò dògbó, yóò sì pẹ́ láyé gẹ́gẹ́ bí ti igi orógbó.

**Obì:** Yorùbá gbà pé obì níí bi ikú àti àrùn dànù, nítorí èyí wọn a máa fi obì wúre fún ìkókó pé obì yóò bi ikú àti àrùn dànù nílé ayé rẹ̀.

Ọ̀kọ̀ọ̀kan ni baálé tàbí ìyáálé yóò máa fi nǹkan wọ̀nyí ṣàdúrà fún ọmọ, bí ó ti ń ṣe àdúrà náà ni yóò sì máa fi ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn fún ìyá ọmọ jẹ tàbí kí ó fi rá ọmọ lẹ́nu. Ìgbàgbọ́ Yorùbá ni pé ìyá yìí ń bá ọmọ rẹ̀ jẹ àwọn nǹkan wọ̀nyí ni àti pé ọmọ náà yóò mú wọ́n nínú ọyàn ìyá rẹ̀.

**4.5 Àyípadà tí ó dé bá àṣà ìsọmọlórúkọ**

Àyípadà púpọ̀ ti dé bá bí Yorùbá ṣe ń sọmọlórúkọ lóde òní. Ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn àti àṣà òkèdèrè ni ó ṣe okùnfà àyípadà wọ̀nyí.

1. Ọ̀pọ̀ kò ní ìgbàgbọ́ nínú lílo àwọn èròjà ìsọmọlórúkọ mọ́, ohun àìlọ́làjú àti ìwà ìbọ̀rìṣà ni wọ́n kà á sí.

2. Ìlànà ẹ̀sìn Kírísítẹ́ẹ̀nì tàbí Ìsìláàmù ni a ń tẹ̀lé púpọ̀ fún ìsọmọlórúkọ lóde òní. Àdúrà àti ìwàásù tàbí wáàsí ni ó máà ń wáyè tí jíjẹ àti mímu yóò sì tẹ̀lé e.

3. Àwọn òbí le dájọ́ ayẹyẹ ìkómọjáde lọ́tọ̀ yàtọ̀ sí ọjọ́ keje, ìkẹjọ tàbí ìkẹsàn-án.

4. Ọ̀pọ̀ orúkọ tí àwọn ènìyàn ń sọ ọmọ wọn lóde-òní ló gbé ẹ̀sìn Kírísítẹ́ẹ̀nì tàbí Ìsìláàmù rù.

Ó jẹ́ ohun ìwúrí fún ni ṣá pé bí àṣà ìsọmọlórúkọ tilẹ̀ ti pa àwọ̀ dà, síbẹ̀ àṣà náà kò tí ní àwùjọ Yorùbá.

## 5.0 Ìsọníṣókí

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti sọ nípa ìdí tí a fi ń sọ ọmọ ní orúkọ, ètò ìsọmọlórúkọ ní ayé àtijọ́ ní ilẹ̀ Yorùbá, àwọn ohun tí a fi ń ṣọ ọmọ lórúkọ, ohun tí àwọn nǹkan ìsọmọlórúkọ wọ̀nyí dúró fú ní ọ̀kọ̀ọ̀kan, àti àyípadà tí ó dé bá àṣà ìsọmọlórúkọ lóde òní.

## 6.0 Iṣẹ́ Síṣe

i. Sọ bí a ti ń ṣe ètò ìsọmọlórúkọ ní ayé àtijọ́ ní ṣókí.

ii. Sọ àyípadà mẹ́rin tí ó dé bá àṣà ìsọmọlórúkọ lónìí.

iii. (a) Se àlàyé ohun tí àkọsẹ̀jayé/ẹsẹ̀ǹtayé túmọ̀ sí.

(b) Báwo ni ó ṣe ṣe pàtàkì sí nínú ètò ìsọmọlórúkọ Yorùbá?

**Commented [OO2]:** Ìbéèrè wọ̀nyí tip ọ̀ jù. Méjì sí mẹ́ta tit ó. Ditto sí àwọn módù yòókù.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Adéoyè, C. L. (1979). *Àṣà àti Ìṣe Yorùba.* Ìbàdàn: Oxford University Press.

Dáramọ́lá O. & Jẹ́jẹ́ A. (1967). *Àṣà Àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn: Oníbọnòjé Press Limited.

Ládélé, T.A.A. *et al* (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ìbàdàn: Gavima Press.

**MÓDÙ KEJÌ:** **Ìsọ̀rí Orúkọ Yorùbá 1**

**Ìpín Kìíní:** **Orúkọ Àbísọ**

**Àkòónú**

**1.0 Ìfáárà**

Orúkọ Yorùbá pọ̀ lọ jara, onírúurú ìsọ̀rí sì ni àwọn orúkọ wọ̀nyí. Ọ̀kan pàtàkì ni ìsọ̀rí orúkọ àbísọ jẹ́. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ó jíròrò lórí oríṣìíríṣìí orúkọ àbísọ Yorùbá.

**2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn**

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí akẹ́kọ̀ó yóò le:

- ṣàlàyé orúkọ àbísọ
- sọ àwọn ìsọ̀rí orúkọ àbísọ
- dá orúkọ àbísọ tó jẹ mọ́ ìdílé
- dá orúkọ àbísọ tó fi Ìdílé Ọlá àti Oyè hàn
- dá orúkọ àbísọ tó jẹ mọ́ ọmọ
- dá orúkọ àbísọ tó jẹ mọ́ Iṣẹ́

**3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú**

1. Kín ni orúkọ àbísọ?
2. Sọ àwọn ìsọ̀rí orúkọ àbísọ Yorùbá tí o mọ̀.
3. Da orúkọ àbísọ mẹ́fà tí ó jẹ mọ́:
    - i. Ìdílé
    - ii. Ọmọ
    - iii. Ìdílé Ọlá àti Oyè
    - iv. Iṣẹ́

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

## 4.1 Kín ni Orúkọ Àbísọ?

Orúkọ àbísọ ni orúkọ tí a tẹ̀ mọ́ ọmọ lára. Ọmọ Yorùbá kì í jẹ́ orúkọ ẹyọ kanṣoṣo lásán, àmọ́ lára àwọn orúkọ wọ̀nyí, ó ní èyí tí a fi máa ń pe ọmọ jù. Èyí ni orúkọ àbísọ ọmọ náà.

## 4.2 Ìsọ̀rí Orúkọ Àbísọ

Adéoyè (1982) pín àwọn orúkọ àbíṣọ Yorùbá sí ìsọ̀rí márùn-ún wọ̀nyí:

i. Orúkọ àbísọ ọmọ tí ó jẹmọ́ ìdílé ọmọ tí ó sì farapẹ́ ọmọ lásán.

ii. Orúkọ àbísọ tí ó jẹmọ́ ọmọ tí ó sì farapẹ́ ìdílé ọmọ lásán.

iii. Orúkọ àbísọ tí ó fi ìdílé Ọlá àti ti Ìjòyè hàn.

iv. Orúkọ àbísọ tí ó fi iṣẹ́ ìdílé hàn.

v. Orúkọ àbísọ tí ó fi ẹ̀sìn ìdílé hàn.

Nínú ìdánlẹ́kọ̀ọ́ yìí, ìsọ̀rí mẹ́rin ni a pín orúkọ àbísọ Yorùbá sí. Àwọn ìsọ̀rí náà ni orúkọ àbísọ tí ó jẹ mọ́ Ìdílé, èyí tí ó jẹ mọ́ Ọmọ, èyí tí ó tí ó fi Ìdílé Ọlá àti Oyè hàn, àti èyí tí ó jẹ mọ́ Iṣẹ́.

## 4.3 Orúkọ Àbísọ tó jẹ mọ́ Ìdílé

Ìsọ̀rí orúkọ àbísọ wọ̀nyí jẹ mọ́ ìdílé. Èyí lè jẹ́ ti ìdílé kí ó fara pẹ́ ọmọ tàbí kí ó jẹ mọ́ ọmọ kí ó sì fara pẹ́ ìdílé ọmọ yìí. Àwọn orúkọ yìí tí ó jẹ́ ti ọkùnrin àti obìnrin, bẹ́ẹ̀ náà ni a sì ní awọn tí takọtabo ń jẹ́. Àpẹẹrẹ àwọn orúkọ àbísọ ti ìdílé tí ó fara pẹ́ ọmọ ni ìwọ̀nyí fún ọkùnrin:

| | | |
|---|---|---|
| Láníyọnu | - | Ìyọnu pọ̀ nínú ọlá |
| Ìyápọ̀ | - | Òpọ̀ ìyà ni ìdílé ti jẹ sẹ́yìn |
| Oyèníyà | - | Ọ̀pọ̀ ìyà àti ẹ̀gbin ni ó ń bẹ nínú oyè |
| Kúrunmí | - | Ikú ti run ìdílé |
| Fìjàbí | - | Ọmọ tí ìdílè jà lé lórí kí wọ́n tó bí i |
| Kúmólú | - | Ikú mú olú tàbí akin inú ìdílé lọ |
| Ọ̀tẹ́gbẹ̀yẹ | - | Ọ̀tẹ̀ gba ẹyẹ tàbí ogo ìdílé lọ |

Kúpẹlẹ́yẹ - Ikú pa ẹlẹ́yẹ tàbí ẹni tí ìdílé gbójúlé

Orúkọ tí ó jẹ́ ti àwọn obìnrin nìyí:

Oníkẹ̀ẹ́pọ̀ - Gbogbo àwọn tó ń ṣe ìkẹ́ tàbí tọ́jú ìdílé wà láàyè

Oyèláròkò - Ó ní ìgbà tí oyè yí kan ìdílé

Oníkẹ̀ẹ́pọ̀ - Àwọn tí ó ń ṣe ikẹ́ tàbí tọ́jú ìdílé pọ̀

Mọ́ríyebá - Ọmọ bá ọ̀pọ̀ ọrọ̀ tàbí ohun ìní nínú ìdíle

Ó yẹ kí á mọ̀ pé a ní ìsọ̀rí orúkọ yìí tí takọtabo ń jẹ́. Ápẹẹrẹ ni:

Ọmọ́tánbàjẹ́ - Ọmọ mú ìbàjẹ́ òbí tàbí ti ìdílé kúrò

Ìbídàpọ̀ - Ọmọ da ìdílé méjì pọ̀

## 4.4 Orúkọ Àbísọ tó jẹ mọ́ Ọmọ

Àwọn orúkọ ọkùnrin tí ó jẹ mọ́ ọmọ ni ìwọ̀nyí:

Ọmọ́jùwá - Ọmọ níye lórí ju ìwà lọ

Ọmọ́kówàjọ - Ọmọ kó ìwà mọ̀lẹ̀bí jọ

Onípẹ̀ẹ́dé - Ẹni tí yóò ṣìpẹ̀ tàbí tu ìdílé nínú ti dé

Ọmọ́pẹ́ńnú - Ọmọ́ pẹ́ ní inú ìyá rẹ̀ ju oṣù mẹ́sàn-án lọ

Ìsọ̀rí orúkọ yìí tí ó jẹ́ ti àwọn obìnrin ni ìwọ̀nyí:

Ọmọ́déere - Ọmọ́ dé sí ayé rere, ó dé sí àsìkò tí ó dára

Ọmọ́désíre - Omọ dé sí inú ire, ó dé sí ìgbà tí ó dára

Moṣebọ́látán - Àṣẹ́ ọlá sì tún kù nígbà tí mo rò pé ó ti tán

Ọmọtéjì - Ọmọ kanṣoṣo yìí tó ọmọ méjì

Ọmọ́táájò - Ọmọ yẹ fún aájò, ọmọ ṣe iyebíye láti kẹ́

Ọmọ́táyọ̀ - Ọmọ tó yọ̀ fún

Omọ́dùúnbí - Ọmọ dùn púpọ̀ láti bí sí ayé

Ọmọ́tóókẹ́ - Ọmọ tó láti kẹ́

Ọmọ́bóníkẹ̀ẹ́ - Ọmọ bá àwọn tí yóò kẹ́ ẹ nínú ìdílé

Ọmọ́tóyọ̀sí - Ọmọ to ohun tí a ó máa yò lé lórí

Ìsọ̀rí orúkọ yìí náà ní èyí tí takọtabo ń jẹ́:

Ayọ̀bámi - Ayọ̀ bá ìdílé

Ṣiyanbọ́lá - Ọmọ yan wá sáyé wá bá ọlá

Ọlárìinre - Ọlá rin sí ibi tí ó dára

Ayọ̀kúnnú - Ayọ̀ pọ̀ nínú mọ̀lẹ́bí

## 4.5 Orúkọ Àbísọ tí ó fi Ìdílé Ọlá àti Oyè hàn

Ìsọ̀rí orúkọ tí ó fi ìdílé ọlá àti oyè hàn a sábà máa bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú Adé, Ọlá, Oyè àti Olú. Bí ìsọ̀rí orúkọ yìí ti ní orúkọ tí ó wà fún ọkùnrin àti obìnrin náà ni ó ní ti takọtabo.

### 4.5.1 Orúkọ Adé

| ***Ọkùnrin*** | ***Obìnrin*** |
|---|---|
| Adéyẹmí | Adéòtí |
| Adérògbà | Fadérera |
| Adétúnjí | Adépèlé |
| Adétáyọ̀ | Adédọjà |
| Gbádégẹṣin | Adénínhún |
| Adéníran | Adéòmí |

Commented [OO3]: Let it be bold

Orúkọ ‘Adé’ tí ó wà fún ọkùnrin àti obìnrin ni: Adéwùmí, Adédigba, Adérójú, Adédùntán, abbl.

Ó yẹ kí á mọ̀ pé kì í ṣe gbogbo orúkọ tí ó bá ‘Ade’ lọ ni ó je ti ìdílé ọba tàbí ti oyè. Ọ̀pọ̀ tí kì í ṣe ìdílé oyè ló ti ń sọ ọmọ wọn ní orúkọ Adé lónìí nítorí pé ó wù wọ́n.

### 4.5.2 Orúkọ Ọlá

| ***Ọkùnrin*** | ***Obìnrin*** |
|---|---|
| Ọláwálé | Ọláòtí |
| Ọláwọlé | Ọládoyin |
| Ọládìgbòlù | Ọlánìkẹ̀ẹ́ |
| Ọlánipẹ̀kun | |

Lára orúkọ ọlá tí ó wà fún takọtabo ni Ọládùúní, Ọláwùmí, Ọlárìinre, Ọládùntán, Ọlájíire, abbl.

**4.5.3 Orúkọ Oyè**

| ***Ọkùnrin*** | ***Obìnrin*** |
|---|---|
| Oyèélẹ́kàn | Oyèéládùn |
| Oyèélẹ́sẹ | Oyèéníkẹ̀ẹ́ |
| Oyèétúnjí | Oyèédoyin |
| Oyèérìndé | Oyèémọ́milára |
| Oyèédélé | Oyèéládùn |

Àwọn orúkọ Oyè tí ọkùnrin àti obìnrin ń jẹ́ ni Oyèéyẹmí, Oyèébọ́lá, Oyèbọ́ádé, Oyèéláròkò, abbl.

**4.5.4 Orúkọ Olú**

Commented [OO4]: O yẹ kí àlàyé ráńpẹ́ wà lórí èyí

| ***Ọkùnrin*** | ***Obìnrin*** |
|---|---|
| Olúwùsì | Olúfúnmiláyọ̀ |
| Olúdé | Olúkẹ́mi |
| Olúbí | Olúyẹ́misí |
| Olúwọlé | Olúrántí |
| Olúwùsì | Olúdoyin |
| Olúṣùtàn | |
| Olúkúnlé | |

Lára àwọn orúkọ Olú tí ọkùnrin àti obìnrin ń jẹ́ ni Olúbùnmi, Olúṣọlá, Olúfẹ́mi, Olúbísí, Olúyẹmí, Ọláolú, àti Olúdélé.

**4.6 Orúkọ Àbísọ tó jẹ mọ́ Iṣẹ́**

Ọ̀pọ̀lọpọ̀ nínú àwọn orúkọ Yorùbá ni ó jẹ mọ́ iṣẹ́. Onírúurú ni iṣẹ́ tí àwon Yorùbá ń ṣe. Lára àwọn iṣẹ́ wọn tí orúkọ hànde nínú wọn ni iṣẹ́ ìlù lílù/iṣẹ́ àyàn, gbẹ́nàgbẹ́nà, ọdẹ, àgbẹ̀dẹ, abbl.

**4.6.1 Iṣẹ́ Ìlù lílù/Àyàn**

| ***Ọkùnrin*** | ***Obìnrin*** |
|---|---|
| Àyántúnjí | Àyánfúnnkẹ́ |
| Àyánlàdé | Àyánbánkẹ́ |
| Àyándélé | Àyánwùmí |
| Àyánbọ̀dé | Àyándùúnní |
| Ọ̀pátúnjí | Ọ̀pārónkẹ́ |
| Ọ̀párìndé | Ọ̀pákẹ́mi |
| Ọ̀pákúnlé | Àyántutù |
| Àyányẹmí | Àyánbùnmi |

**4.6.2 Iṣẹ́ Gbẹ́nàgbẹ́nà**

| ***Ọkùnrin*** | ***Obìnrin*** |
|---|---|
| Ọnàbólú | Ọnàwùmí |
| Ọnànúgà | Ọnàbùnmi |
| Ọnàtúnjí | Ọnàyẹmí |
| Ọnàbánjọ | Ọnàyínká |
| Ọnàníyì | Ọnàyẹni |
| Ọnàjídé | Ọnàrónkẹ́ |
| Ọnàkúnlé | Ọnàfúnnkẹ́ |

**4.6.3 Iṣẹ́ Ọdẹ**

| ***Ọkùnrin*** | ***Obìnrin*** |
|---|---|
| Ọdẹ́bùnmi | Ọdẹ́dùntán |
| Ọdẹ́tómi | Ọdẹ́kẹ́mi |
| Ọdẹ́rìndé | Ọdẹ́tọ̀míwá |
| Ọdẹ́wọlé | Ọdẹ́nínhún |
| Ọdẹ́túndé | Ọdẹ́fúnntọ́ |
| Ọdẹ́wálé | Ọdẹ́bánkẹ́ |

| | |
|---|---|
| Ògúnfẹ́mi | Ògúnwùmí |
| Ògúnyẹmí | Ògúnkẹ́mi |

### 4.6.4 Iṣẹ́ Àgbẹ̀dẹ

| ***Ọkùnrin*** | ***Obìnrin*** |
|---|---|
| Ògúnlàdé | Mofógùnúnkẹ́ |
| Ògúnwùsì | Ògúnkẹ́mi |
| Ògúnsọlá | Mosádògún |
| Ògúnníyì | Ògúntutù |
| Adéògún | Ògúnbánkẹ́ |
| Ọláògún | Mofógùúnkẹ́ |
| Adéògún | Ògúntómi |

**Commented [OO5]:** un-ún

## 5.0 Ìsọnìṣókí

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti ṣàlàyé ohun tí Orúkọ Àbísọ jẹ́. A fi hàn pé ìsọ̀rí orúkọ àbísọ pín sí oríṣìí mẹ́rin. Àwọn wọ̀nyí ni orúkọ àbísọ tó jẹ mọ́ ìdílé, orúkọ àbísọ tó jẹ mọ́ ọmọ, orúkọ àbísọ tó fi Ìdílé Ọlá àti Oyè hàn, àti orúkọ àbísọ tó jẹ mọ́ iṣẹ́. A fi onírúurú àpẹẹrẹ gbe ìsọ̀rí kọ̀ọ̀kan lẹ́sẹ̀.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

i. Ṣe àlàyé ohun tí à ń pè ní Orúkọ Àbísọ.
ii. Ìsọ̀rí mélòó ni a pín Orúkọ Àbísọ sí?
iii. Ṣe àlàyé ìsọ̀rí wọ̀nyí ní ṣókí pẹ̀lú àpẹẹrẹ.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Adéoyè, C.L. (1979). *Àṣà àti Ìṣe Yorùba.* Ìbàdàn: Oxford University Press.

Dáramọ́lá, O. & Jẹ́jẹ́, A. (1967). *Àṣà Àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn: Oníbọnòjé Press Limited.

Ládélé, T.A.A. *et al* (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ìbàdàn: Gavima Press.

**Ìpín Kejì:** **Orúkọ Ẹ̀sìn Ìbílẹ̀**

Commented [OO6]: Yọ èyí kúrò, kí ó sì rí bẹ́ẹ̀ fún àwọn yòókù.

**Àkòónú**

## 1.0 Ìfáárà

Ẹlẹ́sìn ni ìran Yorùbá, abọ̀rìṣà sì ni wọ́n pẹ̀lú. Onírúurú ni àwọn òrìṣà wọn. Mélòó ni a ó kà nínú eyín adípèlé? Tinú ọrún, tòde ọ̀jọ, òjìlénírinwó èrìgì ló forí mulẹ̀ láìyọ. Bí Yorùbá ti ni ọ̀pọ̀lọpọ̀ òrìṣà náà ni wọ́n ní àwọn ìbọ lọ́lọ́kanòjọ̀kan. Lára àwọn òrìṣà Yorùbá ni Ifá, Ṣàngó, Ọya, Egúngún, Ọ̀ṣun, Ògún, Èṣù, Òrìṣà Oko, Olókun, Orò, Ọbàtálá/Òrìṣà Ǹlá, àti àwọn mìíràn. Ìsọ̀rí orúkọ ẹ̀sìn gbajúmọ̀ púpọ̀ ní ilẹ̀ Yorùbá. Ogunlọ́gọ̀ sì ni àwọn orúkọ tí ó ti ara ẹ̀sìn jáde. Àwọn orúkọ ẹ̀sìn a sábà máa bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú orúkọ àwọn òrìṣà wọ̀nyí.

## 2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn

Lẹ́yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí akẹ́kọ̀ọ́ yóò le:

- ṣàlàyé ohun tí orúkọ ẹ̀sìn jẹ́.
- dárúkọ díẹ̀ lára àwọn òrìṣà Yorùbá.
- mọ àwọn ìsọ̀rí orúkọ ẹ̀sìn.
- mọ àwọn orúkọ ẹ̀sìn tó jẹ́ ti ọkùnrin yàtọ̀ sí obìnrin.

## 3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú

1. Ṣàlàyé irú orúkọ tí orúkọ ẹ̀sìn jẹ́.
2. Dárúkọ òrìṣà ilẹ̀ Yorùbá mẹ́wàá tí o mọ̀.
3. Sọ ìsọ̀rí orúkọ ẹ̀sìn mẹ́rin pẹ̀lú àpẹẹrẹ.

## 4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́

### 4.1 Kín ni Orúkọ Ẹ̀sìn?

Orúkọ ẹ̀sìn ni èyí tí ó jẹyọ láti ara òrìṣà tàbí ìbọ kan pàtó. Orúkọ òrìṣà tàbí ìbọ náà ni ó sábà máa ń bẹ̀rẹ̀ irú orúkọ bẹ́ẹ̀.

### 4.2 Ìsọ̀rí Orúkọ Ẹ̀sìn Ìbílẹ̀

Òrìṣà kọ̀ọ̀kan ni a fi pín àwọn orúkọ ẹ̀sìn sí ìsọ̀rí. Àwọn òrìṣad wọ̀nyí ni Ifá/Ọ̀rúnmìlà, Ṣàngó, Èṣù, Ọya, Egúngún, Ọ̀ṣun, Ògún, Òrìṣà Oko, Olókun, Orò, Ọbàtálá/Òrìṣà Ǹlá,

### 4.3 Orúkọ Ifá/Ọ̀rúnmìlà

Àwọn onífá ni ó máa ń jẹ́ orúkọ mọ́ Ifá lára. Orúkọ wọn a máa bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú Ifá, Awo tàbí Odù. Ní ọ̀pọ̀ ìgbà, bí orúkọ bá bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú 'Ifá', a kì í sábà pe 'Ifá' jálẹ̀, 'Fá' tí ó jẹ́ àkékúrú ni a sábà máa ń pè. Bí àpẹẹrẹ, dípò "Ifáwùmí", "Fáwùmí" ni a máa ń pè. Díẹ̀ nínú orúkọ ẹ̀sìn Ifá ti ọkùnrin àti obìnrin ni ìwọ̀nyí.

| ***Ọkùnrin*** | ***Obìnrin*** |
|---|---|
| Fáwọlé | Fádùnúnsìn |
| Fáṣínà | Fáṣeékẹ́ |
| Fáwọyin | Fáwẹ̀mímọ́ |
| Fátúndé | Fábọ̀lá |
| Fálànà | Fáyọ̀yin |
| Fádèyí | Fáwẹ̀dé |
| Fáwòmí | Fáyínká |
| Fábọ́rọ̀ | Fáṣìkẹ́mi |
| Olódùúdé | Fáwùmí |
| Odùúlànà | Awóṣeékẹ́ |
| Odùúgadé | Awobùnmi |
| Odùúgbèmí | Odùyẹmí |
| Akódù | Odùúkẹ́mi |
| Awólàdé | |
| Awótúndé | |
| Awóbọ̀dé | |
| Awólérè | |

Commented [OO7]: ùn-ún

### 4.4 Orúkọ Ṣàngó

| *Ọkùnrin* | *Obìnrin* |
|---|---|
| Ṣàngótúndé | Ṣàngóbùnmi |
| Ṣàngólékè | Ṣàngóràntí |
| Ṣàngótòrò | Ṣàngókẹ́mi |
| Ṣàngódìran | Ṣàngóyẹmí |
| Ṣàngólẹ́yẹ | Ṣàngódárà |
| Ṣàngólànà | Ṣàngódoyin |
| Ṣàngódèyí | |
| Ìtíolú | |

### 4.5 Orúkọ Èṣù

| *Ọkùnriṇ* | *Obìnrin* |
|---|---|
| Èṣúgbàyí | Èṣùfúnnbí |
| Èṣúṣèyí | Èṣúrónkẹ́ |
| Èṣúmúyìíwá | Èṣúbùnmi |
| Èṣúlékè | Èṣúkẹ́mi |

### 4.6 Orúkọ Ọya

| *Ọkùnrin* | *Obìnrin* |
|---|---|
| Ọyátórìṣà | Ọyátọ́pẹ́ |
| Ọyátóóbọ | Ọyádárà |
| Ọyáwálé | Ọyáfúnmi |
| Ọyátọ́pẹ́ | Ọyárínú |
| Ọyájúbọ | Ọláọya |
| Ọyádínà | Ọyáwẹ̀mímọ́ |

### 4.7 Orúkọ Egúngún

| *Ọkùnriṇ* | *Obìnrin* |
|---|---|
| Eégúnbíyìí | Ọ̀jẹ́wùmí |
| Eégúnjọbí | Ọ̀jẹ́bùnmi |
| Eégúnlétí | Ọ̀jẹ́kẹ́mi |
| Eégúnyọmí | Ọ̀jẹ́rántí |
| Eégúnwálé | Eégúnyẹmí |
| Ọ̀jẹ́wálé | Eégúnrínú |
| Ọ̀jẹ́dèjì | |
| Ọ̀jẹ́wùmí | |
| Adébọ́jẹ̀ | |

### 4.8 Orúkọ Ọ̀ṣun

| *Ọkùnrin* | *Obìnrin* |
|---|---|
| Ọ̀ṣúnwọlé | Ọ̀ṣúnníwẹ̀ |
| Ọ̀ṣúndárà | Ọ̀ṣúnyẹmí |
| Ọ̀ṣúnyọmí | Ọ̀ṣúnrántí |
| Ọ̀ṣúndípẹ̀ | Ọ̀ṣúnbùnmi |
| Ọ̀ṣúndíyà | Ọ̀ṣúntóókẹ́ |
| Ọ̀ṣúndìran | Ọ̀ṣúnṣọlá |

### 4.9 Orúkọ Ògún

| *Ọkùnrin* | *Obìnrin* |
|---|---|
| Ògúndìímú | Ògúnríyìíkẹ́ |
| Ògúndìràn | Ògúnrántí |
| Ògúndíjọ | Ògúndayọ̀ |
| Ògúndèyí | Ògúnrónkẹ́ |
| Ògúndèjì | Ògúnfúnnkẹ́ |
| Ògúndìran | Ògúnwùmí |

**4.10 Orúkọ Òrìṣà Oko**

| *Ọkùnrin* | *Obìnrin* |
|---|---|
| Ṣódíyà | Ẹfúnyẹlá |
| Ṣódípẹ̀ | Ẹfúnróyè |
| Ṣówẹ̀mímọ́ | Ẹfúnyẹmí |
| Ṣóyínká | Ẹfúnrónkẹ́ |
| Ṣódìímú | Ṣórìnọ̀lá |
| Ṣóbọ̀wálé | Ṣóbánkẹ́ |

**4.11 Orúkọ Orò**

| *Ọkùnrin* | *Obìnrin* |
|---|---|
| Oròdìjí | Ìtáyẹmi |
| Oròwálé | Oròókẹ́mi |
| Abíórò | Oròóyẹmí |
| Oròókúnlé | Oròóbùnmi |
| Ìtásanmí | Ìtádìjí |
| Ìtáwuyì | Ìtáwùmí |
| Ìtábíyìí | |

**4.12 Orúkọ Ọbàtálá**

| *Ọkùnrin* | *Obìnrin* |
|---|---|
| Òrìṣàdáre (Ṣádáre) | Òrìṣàbùnmi |
| Òrìṣàtọ̀lá (Ṣátọ̀lá) | Tàwẹ̀dé |
| Òrìṣàtọ́lá | Òrìṣàrínú |
| Òrìṣàtólú | Erinlẹ̀ |

## 5.0 Ìsọniṣókí

Pàtàkì ni orúkọ ẹ̀sìn ìbílẹ̀ jẹ́ nínú orúkọ Yorùbá nítorí pé ọ̀gọ̀ọ̀rọ̀ orúkọ ni ó ti inú ẹ̀sìn ìbílẹ̀ wọ̀nyí jáde. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti ṣàlàyé ohun tí orúkọ ẹ̀sìn jẹ́. Onírúurú ẹ̀sìn ìbílẹ̀ ni a tọ́ka sí pẹ̀lú àpẹẹrẹ àwọn orúkọ wọn. A pààlà láàrin àwọn orúkọ òrìṣà tí ọkùnrin àti obìnrin ń jẹ́. Àwọn òrìṣà Yorùbá mọ́kànlá tí ó gbajúmọ̀ ni a sọ̀rọ̀ lórí orúkọ wọn. Àwọn òrìṣà wọ̀nyí ni Ifá, Ṣàngó, Ọya, Egúngún, Ọ̀ṣun, Ògún, Èṣù, Òrìṣà Oko, Olókun, Orò, àti Ọbàtálá/Òrìṣà Ńlá. Ó yẹ kí á mọ̀ pé ogunlógọ̀ òrìṣà àti ìbọ ni a kò mẹ́nubà rárá. Àwọn akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè ṣe ìwádìí lórí àwọn wọ̀nyí.

## 6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Ṣàlàyé ṣókí lórí ẹ̀sìn ìbílẹ̀ Yorùbá.
2. Kín ni àbùdá àwọn orúkọ ẹ̀sìn ìbílẹ̀ Yorùbá?
3. Sọ ìsọ̀rí orúkọ ẹ̀sìn ìbílẹ̀ mẹ́fà pẹ̀lú àpẹẹrẹ.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí


Adéoyè, C. L. (1979). *Àṣà àti Ìṣe Yorùba.* Ìbàdàn: Oxford University Press.

Dáramọ́lá O. & Jẹ́jẹ́ A. (1967). *Àṣà Àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn: Oníbọnòjé Press Limited.

Ládélé, T.A.A. *et al* (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ìbàdàn: Gavima Press.

**Ìpín Kẹta: Orúkọ Àmútọ̀runwá**

**Àkòónú**

**1.0 Ìfáárà**

Ọ̀kàn pàtàkì kan ni orúkọ àmútọ̀runwá jẹ́ nínú àwọn orúkọ Yorùba. Ọ̀nà tí ìkókó gbà wáyé àti bí a ṣe bí i máa ń fi orúkọ àmútọ̀runwá hàn. Fún ìdí èyí, ọ̀pọ̀ irú orúkọ yìí kì í ṣe àjèjì fún ojúlówó ọmọ Yorùbá. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ó ṣe àlàyé kíkún pẹ̀lú ọ̀pọ̀ àpẹẹrẹ nípa àwọn orúkọ àmútọ̀runwá.

**2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn**

Lẹ̀yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:

- sọ ìtumọ̀ orúkọ àmútọ̀runwá.
- dárúkọ oríṣìíríṣìí orúkọ àmútọ̀runwá.
- ṣàlàyé ìtumọ̀ àwọn orúkọ àmútọ̀runwá wọ̀nyí.

**3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú**

1. Ṣàlàyé irú orúkọ tí à ń pè ní orúkọ àmútọ̀runwá.
2. Dárúkọ oríṣìíríṣìí orúkọ àmútọ̀runwá méjọ tí o mọ̀.
3. Sọ ìtumọ̀ àwọn orúkọ àmútọ̀runwá mẹ́jẹ̀ẹ̀jọ tí o dárúkọ.

**4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

**4.1 Kín ni Orúkọ Àmútọ̀runwá?**

Orúkọ Àmútọ̀runwá jẹ́ èyí tí a ti mọ̀ mọ ọmọ ní kété tí a bá ti bí i sílé ayé. Orúkọ yìí jẹ́ èyí tí a ti ipasẹ̀ ìbí ọmọ náà mọ̀. Nípasẹ̀ bí a ṣe bí ọmọ, ọ̀nà tí a gbà bí i, iye ọmọ tí a bí, ibi tí a bí i sí, ìgbà tí a bí i, irú ọmọ tí a bí ṣaájú rẹ̀, ìwà àti ìṣe rẹ̀ nígbà tí a bí i, ìrísí rẹ̀, abbl. ni ó máa ń tọ́ka orúkọ àmútọ̀runwá fún ọmọ.

### 4.2. Àpẹẹrẹ Orúkọ Àmútọ̀runwá

Ọ̀kan-ò-jọ̀kan ni orúkọ àmútọ̀runwá ti ó wà ní ilẹ̀ Yorùbá. Àpẹẹrẹ àwọn orúkọ yìí ni: Abíọ́dún, Àbíọ́nà, Àbíìbá, Táíwò, Kẹ́hìndé, Ìdòwú, Àlàbá, Ìdògbé, Ẹ̀ta Òkò/Abẹ́ta, Ìgè, Àjàyí, Òjó, Àìná, Ọ̀kẹ́, Òkè, Dada, Olúgbódi, Babátúndé, Babárìndé, Babáyẹmí, Babáyẹjú, Babárímisá, Babáyẹlé, Yétúndé, Yéjídé, Yésìdé, Yéwándé, Ìyábọ̀dé, Yeyerímisá, Tàlàbi, Sàlàkọ́, Òní, Ọ̀la, Ọ̀tunla, àti bẹ́ẹ̀ lọ.

### 4.3 Àlàyé Orúkọ Àmútọ̀runwá kọ̀ọ̀kan

Gbogbo orúkọ àmútòrunwá ni ó ní ìdí tí wọn fi ń jẹ́ bẹ́ẹ̀. Ní ìpín yìí a ó ṣe àlàyé orúkọ kọ̀ọ̀kan ní kíkún.

#### 4.3.1 Táíwò, Kẹ́hìndé àti Ẹ̀ta Òkò tàbí Abẹ́tà

**Táíwò:** Orúkọ ìbejì ni Táíwò. Àpèjá orúkọ yìí ni "Tọ́ ayé wò". A tún máa ń pè é ní Táyéwò tàbí Táyé. Èyí ni ọmọ tí ó bá kọ́kọ́ dáyé nínú àwọn ìbejì yálà ó jẹ́ ọkùnrin tàbí obìnrin. Yorùbá gbàgbọ́ pé ìránṣẹ́ ni Táíwò jẹ́ níti pé ìkejì rẹ̀ rán an pé kí ó wá wo bí ayé ṣe rí ni. Bí Táíwò bá ké "wẹ́nẹ̀n, wẹ́nẹ̀n, wẹ́nẹ̀n", ó ń jíṣẹ́ fún èkejì rẹ̀ pé kí ó máa bọ̀ pé ayé dùn nìyẹn.

**Kẹ́hìndé:** Orúkọ ọmọ ìbejì tí a bí ṣìkejì ni Kẹ́hìndé. Òun ni àtẹ̀lé fún Táíwò. Yòrùbá gbà pé Kẹ́hìndé ni ẹ̀gbọ́n àti pé òun ni ó rán Táíwò láti wá tọ́ ayé wò. Ìdí nìyí tí wọ́n fi máa ń kì í pé 'Ọmọ kẹ́hìn dé ó gbẹ̀gbọ́n'. Takọ tabo ni ó ń jẹ́ Kẹ́hìndé.

**Ẹ̀ta Òkò tàbí Abẹ́tà:** Bí a bá bi ọmọ mẹ́ta lẹ́ẹ̀kanṣoṣo, ìbẹta ni a máa ń pè wọ́n. Táiwò ni àkọ́kọ́, Kẹ́hìndé ni ìkejì, Ẹ̀ta Òkò tàbí Abẹ́ta ni èyí tí ó ṣìkẹta yálà lọ́kùnrin tàbí lóbìnrin.

#### 4.3.2 Ìdòwú, Àlàbá, Ìdògbé, Ìdòha

Ìsòwọ́ àwọn orúkọ yìí ní àjọṣe pẹ̀lú Ìbejì. Wọ́ jẹ́ àtẹ̀lé sí àwọn ìbejì.

**Ìdòwú:** Ọmọ tí a bá bí tẹ̀lé àwọn ìbejì ni a máa ń pè ní Ìdòwú. Ìdòwú lè jẹ́ ọkùnrin tàbí obìnrin. Yorùbá a máa pe Ìdòwú ní "Èṣù lẹ́yìn ìbejì". Ìdí ni pé wọ́n gbà pé ọmọ tí a bá bí lẹ́yìn ìbejì a máa le púpọ̀. Wọn a máa kọrin ki Ìdòwú báyìí pé:

Ìdòwú ògbo
Abìkere létí
Bó bá sùn lọ
A sì máa játọ́

**Àlàbá:** Ọmọ tí a bá bí tẹ̀lé Ìdòwú ni a ń pè ní Àlàbá. Tọkùnrin tobìnrin náà ni a máa ń sọ ní Àlàbá. Gẹ́gẹ́ bí èrò Adéoyè (1982:11), ọmọ tí a bi tẹ̀lé Ìdòwú tí ó bá jẹ́ obìnrin nìkan ni a máa ń pè ní Àlàbá. Ní òde òní, èyí kò rí bẹ́ẹ̀ mọ́.

**Ìdògbé:** Èyí ni ọmọ tí ó bí tẹ̀lé Àlàbá. Orúkọ ọmọ ọkùnrin ni Ìdògbé. Adéoyè (1982:11) tún wòye pé ọmọ obìnrin ti ń jẹ́ Ìdògbé lóde òní.

**Ìdòha:** Ọmọ tí a bí tẹ̀lé Ìdògbé ni à ń pè ní Ìdòha yálà ó jẹ́ ọkùnrin tàbí obìnrin. Àkíyèsí wa ni pé orúkọ yìí ti di ìkàsìn lóde òní. Ọ jẹ́ ọ̀kan lára àwọn orúkọ àmútọ̀runwá tí a kò fi sọ ọmọ mọ́.

**4.3.3 Ìgè, Àjàyí, Òjó, Àìná, Ọ̀kẹ́, Òkè, Dada, Olúgbódi**

**Ìgè:** Ọmọ àtẹsẹ̀bí ni à ń sọ ní Ìgè. Èyí ni ọmọ tí ó jẹ́ pé ẹsẹ̀ ni ó kọ́kọ́ yọ síta dípò orí. Ìrú ìbí báyìí gba ẹlẹgẹ́ púpọ̀, ó sì lè mú ẹ̀mí ìyá rẹ̀ lọ.

**Àjàyí:** Ọmọ tí ó bá dojú bolẹ̀ nígbà tí a bí i tán ni à ń sọ ní Àjàyí. Tọkùnrin tobìnrin ni à ń sọ ní Àjàyí.

**Òjó:** Ọmọ tí ó bá gbe ibi kọ́rùn wáyé, tí o sì jẹ́ ọkùnrin ni à ń pè ní Òjó.

**Àìná:** Ọmọ tí ó bá gbe ibi kọ́rùn wáyé, tí o sì jẹ́ obìnrin ni à ń pè ní Àìná.

**Ọ̀kẹ́:** Ọmọ́ tí a bí tí ó wà nínú àpò tàbí táánná ní à ń pè ní Ọ̀kẹ́.

**Òkè:** Ọmọ tí ó bá dákú nígbà tí wọ́n bá ń rọ ọ́ tàbí dá a lágbàálẹ̀ ní à ń pè ní Òkè.

**Dàda:** Dàda ni ọmọ tí irun orí rẹ̀ bá ta kókó tàbí tí irun orí rẹ̀ bá hunjọ. A máa ń ki Dàda ní "Dàda àwúru, olówó ẹyọ".

**Olúgbódi:** Ọmọ tí ó ní ìka mẹ́fà ní ọwọ́, ẹsẹ̀ tàbí ní tọwọ́tẹsẹ̀ ni à ń pè ní Olúgbódi. Ìka kẹfà yìí kì í tóbi, a máa yọ ní ẹ̀gbẹ́ ọmọńdinrín. Ọmọńdinrín ni ìka ọwọ́ tàbí ti ẹsẹ̀ tí ó kéré jù. Yorùbá a máa ki Olúgbódi ní "ọ̀rọ̀ abẹsẹ̀ mẹ́fà".

### 4.3.4 Abíọ́dún, Àbíọ́nà, Àbíìbá

**Àbíọ́dún:** Orúkọ ọmọ tí a bí nígbà ọdún ni a ń pè ní Abíọ́dún. Ọmọ yìí lè jẹ́ ọkùnrin tàbí obìnrin. Ọdún yìí lè jẹ́ ọdún Ifá, ọdún Eégún, ọdún Òrìṣà Oko, ọdún Ògún, ọdún Orò, ọdún Odòjé, ọdún Kérésìmesì, ọdún tuntun, ọdún iléyá, abbl.

**Àbíọ́nà:** Ọmọ tí ìyá rẹ̀ bí sí ojú ọ̀nà ibi tí ìtá rẹ̀ ń lọ ni à ń pè ní Abíọ́nà. Èyí túmọ̀ sí ọmọ tí a bí sí ọ̀nà, yálà ọ̀nà oko, ọ̀nà ọjà, ọ̀nà odò, ọnà ilé, abbl.

**Àbíìbá:** Orúkọ ọmọbìnrin ni Àbíìbá. Ọmọ tí a bí lẹ́hìn ikú baba rẹ̀ ní a máa ń sọ ní Àbíìbá.

### 4.3.5 Abọ́sẹ̀dé, Ọmọ́bọ́sẹ̀dé, Abíọ́sẹ̀, Ọjọ́ọ̀sẹ̀

Orúkọ yìí ni a máa ń sọ ọmọ tí a bá bí ní ọjọ́ ọ̀sẹ̀ Ọbàtálá tí a tún ń pè ní Òòṣàálá (Òrìṣà ńlá). Lóde òní, ọmọ tí a bá bí ní ojọ́ ìsinmi ni a máa ń pè ní orúkọ yìí.

### 4.3.6 Òní, Ọ̀la, Ọ̀tunla

**Òní:** Ọmọ́ tí ó bá kére tàbí bí ó bá wẹ́, tí ó sì máa ń súnkun tọ̀sán tòru ni a máa ń pè ní Òní.

**Ọ̀la:** Ọmọ tí a bá bí lẹ́yìn tí a bí Òní tán ni a máa ń sọ ní Ọ̀la.

**Ọ̀tunla:** Ọ̀tunla ni ọmọ tí a bí tẹ̀lé Ọ̀la.

#### 4.3.7 Babátúndé, Babárìndé, Babáyale, Babáyẹjú, Babárímisá

**Babátúndé:** Èyí ni orúkọ tí a máa ń sọ ọmọ ọkùnrin tí a bá kọ́kọ́ bí lẹ́yìn ikú bàbá àgbà, èyí ni bàbá bàbá ọmọ. A tún lè sọ ọmọ yìí ní Babárìndé.

**Babáyalé:** Èyí ni orúkọ tí a máa ń sọ ọmọ ọkùnrin tí a bá kọ́kọ́ bí lẹ́yìn ikú bàbá àgbà. Bàbá àgbà yìí lè jẹ́ ẹ̀gbọ́n tàbí àbúrò bàbá bàbá ọmọ.

**Babáyẹjú:** Orúkọ yìí ni a máa ń sọ ọmọbìnrin tí a bá kọ́kọ́ bí lẹ́yìn ikú bàbá rẹ̀.

**Babárímisá:** Orúkọ yìí ni a máa ń sọ ọmọkùnrin tí a bá kọ́kọ́ bí lẹ́yìn ikú bàbá rẹ̀.

#### 4.3.8 Yétúndé, Yéjídé, Yésìdé, Yéwándé, Ìyábọ̀dé, Yeyérímisá

**Yétúndé, Yéjídé, Yésìdé, Yéwándé, Ìyábọ̀dé**: Orúkọ obìnrin ni gbogbo àwọn orúkọ wọ̀nyí. Ìwọ̀nyí ni orúkọ tí a máa ń sọ ọmọ obìnrin tí a bá kọ́kọ́ bí lẹ́yìn ikú ìyá àgbà, èyí ni ìyá bàbá ọmọ.

**Yeyerímisá:** Èyí ni orúkọ tí a máa ń sọ ọmọbìnrin tí ìyá rẹ̀ kú nígbà tí a bí i tán.

## 5.0 Ìsọniṣókí

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti a ti ṣàlàyé ohun tí Orúkọ Àmútọ̀runwá jẹ́. A ṣe àtòjọ onírúurú àwọn Orúkọ Àmútọ̀runwá tí Yorùbá máa ń jẹ́. Lẹ́yìn èyí ni a wá ṣe àlàyé orúkọ àmútọ̀runwá kọ̀ọ̀kan láti mọ ìtumọ̀ wọn àti ìdí tí a fi ń sọ orúkọ wọ̀nyí.

## 6.0. Iṣẹ́ Ṣíṣe

1. Kín ni orúkọ àmútọ̀runwá?
2. Dárúkọ orúkọ àmútọ̀runwá mẹ́wàá.
3. Ṣàlàyé ìtumọ̀ àwọn orúkọ àmútọ̀runwá mẹ́wẹ̀ẹ̀wá tí o dárúkọ.

## 7.0 Ìwé Ìtọ́kasí

Adéoyè, C. L. (1979). *Àṣà àti Ìṣe Yorùba.* Ìbàdàn: Oxford University Press.

Dáramọ́lá O. & Jẹ́jẹ́ A. (1967). *Àṣà Àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn: Oníbọnòjé Press Limited.

Ládélé, T.A.A. *et al* (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ìbàdàn: Gavima Press.

**Ìpín Kẹrin: Orúkọ Àbíkú**

**Àkòónú**

**1.0 Ìfáárà**

Àyè ọ̀tọ̀ ni orúkọ àbíkú wà nínú ìsọ̀rí àwọn orúkọ Yorùbá. Ìdí ni pé àrà ọ̀tọ̀ ní àwọn ọmọ tí a ń pè ní àbíkú náà. Àrà ọ̀tọ̀ ni ìbí wọn, onírúurú itú sì ni wọ́n máa ń pa fún àwọn òbí wọn. Yòrùbá gbà pé ìkà àti ọ̀dájú ọmọ ni àbíkú torí bí wọ́n bá ti ń bí i ni yóò máa kú. Ìdí nìyí tí wọ́n ṣe máa ń pè wọ́n ní apàárà torí pé bí ó ṣe ń wá sílé ayé náà ni ó ń padà sájùlé ọ̀run.

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ó ṣe àlàyé kíkún pẹ̀lú ọ̀pọ̀ àpẹẹrẹ nípa àwọn orúkọ tí ó wà fún àbíkú.

**2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn**

Lẹ̀yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:

- ṣàlàyé irú omọ tí a ń pè ní àbíkú.
- sọ ìtumọ̀ orúkọ àbíkú.
- dárúkọ oríṣìíríṣìí orúkọ àbíkú.
- ṣàlàyé orúkọ àbíkú kọ̀ọ̀kan.

**3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú**

1. Irú ọmọ wo ni àbíkú?
2. Ṣàlàyé irú orúkọ tí à ń pè ní orúkọ àbíkú.
3. Sọ orúkọ àbíkú mẹjọ tí o mọ̀ kí o sì sọ ìtumọ̀ wọn.

**4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

**4.1 Ta ni Àbíkú?**

Àbíkú ni ọmọ tí a ń bí, tí ó ń kú, tí a sì tún ń bí i. Irú ọmọ yìí ni a mọ̀ sí elére ọmọ. Gẹ́gẹ́ bí èrò Adeoye (1982:38), Yorùbá a máa pè irú ọmọ yìí ní olówó ọmọ, apàárà, alálọbọ̀,

tàbí ayọ́runbọ̀. Bí tọkọtaya kan bá ṣàgbákò irú ọmọ báyìí, bí wọ́n bá ti ń bí i ni yóò máa kú. Irú ọmọ bẹ́ẹ̀ a máa fi ikú àkútúnkú bẹ́ẹ̀ dá àwọn òbí lágara ni.

Yorùbá kì í sin àbíku ọmọ pẹ̀lú àyẹ́sí. Onírúurú ọ̀nà àbùkù ni wọ́n máa ń gbà sin wọ́n. Wọ́n a máa sin wọ́n sínú igbó, wọn a máa gbé wọn sọnù sínú ìgbẹ́, tàbí kí wọn jó wọn níná. Àwọn òbí lè wò sùnsùn kí wọ́n kán an lápá tàbí lẹ́sẹ̀ kí wọ́n tó sin ín, wọ́n sì lè ṣá a lọ́gbẹ́ tàbí kí wọ́n dá àpá sí i lára. Wọn a máa ṣe èyí fún àbíkú pẹ̀lú ìrètí pé tí ó bá tún wá sáyé kò ní kú mọ́.

Alágbára nínú òògùn ni ìran Yorùbá, wọn a sì máa lo òògùn láti kápá ọmọ yìí. Gbékúdè ni òògùn tí wọ́n fi máa ń de àbíkú ọmọ mọ́lẹ̀ kí ó má baà kú mọ́. Òògùn yìí lè jẹ́ ońdè, ìfúnpá, ìkóbẹ́rẹ́, tàbí gbẹ́rẹ́.

### 4.2 Kín ni Orúkọ Àbíkú?

Orúkọ àbíkú jẹ́ orúkọ ìyàsọ́tọ̀ fún àwọn elére ọmọ tí wọ́n ń kú ní gbogbo ìgbà tí wọ́n bá ti bí wọn. Àwọn ọmọ tí ó jẹ́ alálọbọ̀ tàbí ayọ́runbọ̀ ni àbíkú. Orúkọ àbíkú jẹ́ orúkọ ẹ̀bẹ̀, orúkọ ẹ̀gàn tàbí orúkọ ìṣáátá.

### 4.3 Àpẹẹrẹ Orúkọ Àbíkú

Ọ̀kan-ọ̀-jọ̀kan ni orúkọ tí wọn ń sọ àbíkú ní ilẹ̀ Yorùbá. Díẹ̀ nínú wọn nìyí.

#### 4.3.1 Orúkọ Ẹ̀bẹ̀

| | | |
|---|---|---|
| Jẹ́kínníyì/Jẹ́nníyì | - | Jẹ́kí èmi náà ní iyì |
| Dúrósinmí | - | Dúró nínú aye kí o sinmí lọ́jọ́ alẹ́ |
| Bánjókòó | - | Bá mi jókòó |
| Dúróoríkẹ̀ẹ́ | - | Dúró sí ayé kí o rí ìkẹ́ |
| Dúrótoyè | - | Dúró ti oyè nínú ayé |
| Dúrójayé | - | Dúró kí o jẹ ìgbádùn ayé |
| Málọmọ́ | - | Má ṣe lọ sọ́run mọ́, dúró gbe inú ayé |
| Mábáwọnkú | - | Má ṣe bá àwọn ẹgbẹ́ rẹ kú mọ́ |
| Mákùú | - | Má kú ikú mọ́ |

| | | |
|---|---|---|
| Ayélààgbé | - | Inú ayé ni à á gbé, kì í ṣe ọ̀run |
| Máyùngbẹ́ | - | Má lọ sínú ìgbẹ́ mọ́ |
| Máyungbó | - | Má lọ sínú ìgbó mọ́ |
| Kúkọ̀yí | - | Ikú kọ èyi, ikú kò fẹ́ èyí |
| Àńdùú | - | A ń du ọmọ yìí lọ́wọ́ |
| Arádojo | - | Ara ìyá tàbí tàwọn òbí méjèèjì ti di ojo, ẹ̀rù ń bà wọ́n |
| Kúforíjì | - | Ikú fi orí jì, kí ikú gbẹ́bẹ̀, kí ikú dáríjì |
| Dójútikú | - | Mú kí ojú ti ikú, dá ojú ti ikú |

**4.3.2 Orúkọ Èébú**

| | | |
|---|---|---|
| Mámòórá | - | Má ṣe mú owó àwọn òbí rá, má fi owó àwọn òbí sòfò |
| Tijúikú | - | Ti ojú ikú |
| Akújí | - | Ẹni tí ó kú tí ó tún jí |
| Apààrà | - | Ẹni tí ó ń lọ tí ó ń bọ̀, ẹni tí ó ń pààrà |
| Ẹnúkúnonípè | - | Ó ti sú onípè |
| Kòsọ́kọ́ | - | Kò sí ọkọ́ tí a ó fi gbẹ́lẹ̀ láti sin ọ́ mọ́ |
| Àńwóókọ | - | À ń wá orúkọ tí a ó sọ ọmọ yìí |
| Orúkọtán | - | Kò sí orúkọ mọ́, a kò rí orúkọ tí a ó sọ ọmọ yìí |
| Kòdélẹ̀yírí | - | Kò dé ilẹ̀ yìí rí |
| Kòwárí | - | Kò wá sí ilẹ̀ yìí rí |
| Máko | - | Má ṣe kó mi lẹ́rù lọ |
| Abíiná | - | A ti bí èyí ná |

**4.3.3 Orúkọ Ẹ̀gàn /Ìṣáátá**

| | | |
|---|---|---|
| Kòtóyẹ́ | - | Ọmọ yìí kò tó yẹ́ sí, ọmọ yìí kò ní àpọ́nlé |
| Ajá | - | Ẹranko lásán ni ọmọ yìí, ajá ni |
| Àkísàtán | - | Kò sí àkísà tí a ó fi sin ọmọ mọ́ |
| Ìgbẹ́kọ̀yí | - | Ìgbẹ́ kọ èyí |

**5.0 Ìsọniṣókí**

Àkàndá ọmọ ni àbíkú jẹ́, Yorùbá a sì máa bẹ Ọlọ́run pé kí ọ̀dájú ọmọ má yà lọ́dọ̀ àwọn. Orúkọ àbíkú pé oríṣìíríṣìí. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a wo ìsọ̀rí orúkọ àbíkú mẹ́ta. Àwọn wọ̀nyí ni orúkọ ẹ̀bẹ̀, orúkọ èébú àti orúkọ ẹ̀gàn /ìṣáátá.

**6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe**

1. Irú itú wo ni àbíkú ọmọ máa ń pa?
2. Pín orúkọ àbíkú sí ìsọ̀rí pẹ̀lú àpẹẹrẹ.
3. Dárúkọ orúkọ àbíkú mẹjọ tí o mọ̀.
4. Sọ ìtumọ̀ àwọn orúkọ àbíkú mẹ́jẹ̀ẹ̀jọ tí o dárúkọ.

**7.0 Ìwé Ìtọ́kasí**


Adéoyè, C. L. (1979). *Àṣà àti Ìṣe Yorùba.* Ìbàdàn: Oxford University Press.

Dáramọ́lá O. & Jẹ́jẹ́ A. (1967). *Àṣà Àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn: Oníbọnòjé Press Limited.

Ládélé, T.A.A. *et al* (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ìbàdàn: Gavima Press.

**MÓDÙ KẸTA:** **Ìsọ̀rí Orúkọ Yorùbá 2**

**Ìpín Kìíní:** **Orúkọ-Oríkì**

**Àkòónú**

**1.0 Ìfáárà**

Ọ̀kan pàtàki ni oríkì jẹ́ nínú àwọn orúkọ Yorùbá. Ipò ọ̀wọ̀ sì ni oríkì wà nínú àwọn orúkọ tí a bá sọ ọmọ. Ó yẹ kí a pààlà láàrin oríkì-orúkọ àti ìsọ̀rí ewì alohùn tí a ń pè ní oríkì. Oríkì tí ó jẹ́ ewì ni àkójọpọ̀ àwọn gbólóhùn àti ìpèdè tí a fi ń ṣe àpèjúwe, ṣe àpọ́nlé tàbí ṣe àyẹ́sí ẹnì kan, ìran kan, igi oko, ẹranko, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Oríkì tí ó jẹ́ orúkọ ni à ń sọ̀rọ̀ bá nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, ó sì jẹ́ ọ̀kan lára àwọn orúkọ tí a máa ń sọ ọmọ.

**2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn**

Lẹ̀yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:

- Ṣe àlàyé ohun tí oríkì jẹ́.
- pààlà láàrin orúkọ-oríkì àti oríkì Yorùbá tí ó jẹ́ ewì.
- mọ oríṣìíríṣìí orúkọ-oríkì tí ọkùnrin ń jẹ́.
- mọ oríṣìíríṣìí orúkọ-oríkì tí obìnrin ń jẹ́.

**3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú**

1. Ṣe àlàyé orúkọ-oríkì Yorùbá.
2. Ṣọ ìyàtọ̀ láàrin orúkọ-oríkì àti oríkì Yorùbá.
3. Sọ orúkọ-oríkì mẹ́wàá tí o mọ̀.

**4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

**4.1 Kín ni Orúkọ-oríkì?**

Oríkì ṣe pàtàkì púpọ̀ nínú àwọn orúkọ Yorùbá. Àwọn ẹ̀yà Ọ̀yọ́ Yorùbá tilẹ̀ ka oríkì sí, wọ́n sì mú un ní ọ̀kúnkúndùn púpọ̀. Ọba nínú orúkọ tí ọmọ ń jẹ́ ni oríkì. Orúkọ ọ̀wọ̀ àti iyì tí a fún ọmọ ni oríkì. Ìdí nìyí tí Yorùbá fi máa ń fi àwọn àlejò tàbí àjèjì ààrin wọn ṣẹ̀fẹ̀ pé

‘alórúkọ má lóríkì’ ni wọ́n. Tọkùnrin tobìnrin ni ó máa ń ní oríkì. Oríkì àwọn ọkùnrin a máa fi ìwà agbára, akin àti akọni hàn. Ẹ̀wẹ̀, oríkì ti àwọn obìnrin ń jẹ́ máa ń fi ìfẹ́, ìkẹ́, ìgẹ̀, ìyọ́nú àti ìrètí hàn.

Àyè ọ̀tọ̀ ni Yorùbá to oríkì sí. Oríkì kì í ṣe orúkọ àbísọ tí a fi máa ń peni ní gbogbo ìgbà. Ẹ̀ẹ̀kọ̀ọ̀kan ni a máa ń lo oríkì ọmọ. Àgbàlagbà ní ó sì máa ń pe oríkì ọmọ. Àbúro tàbí irọ̀ ẹni kì í ṣàdéédé máa la oríkì mọ́ni lórí. Kódà oríkì ní àwọn àkókò pàtàkì tí a máa ń lò ó. Àwọn òbí a máa ki ọmọ wọn ní àárọ̀ kùtù hàì nígbà tí wọ́n bá jí. Wọn a máa ki oríkì wọn tí wọ́n bá ń re ìdálẹ̀ tàbí bí wọ́n bá ṣ̀ẹ̀ṣẹ̀ ti ìdálẹ̀ dé. Ìgbà mìíràn tí òbí tàbí àgbà bá fẹ́ bá ọmọ sọ̀rọ̀ pàtàkì, a máa ń fi oríkì pè wọ́n. Bí a bá sì fẹ́ fi ìfẹ́ hàn tàbí kan saárá sí ọmọ fún ohun kan pàtàkì tí ó ṣe, a máa ń pe oríkì rẹ̀. Èyí tí ó tún wọ́pọ̀ ni kí àwọn olólùfẹ́ máa pe oríkì ara wọn láti ṣe àfihàn ìfẹ́ tí wọ́n ní si ara wọn.

## 4.2 Orúkọ-oríkì Ọkùnrin

Orúkọ-oríkì ọkùnrin pọ̀ lọ jàǹtìrẹrẹ. Díẹ̀ nínú wọn niyí.

Àkànjí
Àkànní
Àkànwó
Àkàngbé
Àkànbí
Àkànmú
Àkàndé
Àlàdé
Àlàbí
Àlàní
Àlàmú
Àlàó
Àjàní
Àjàgbé
Àjàsá

Àjàdí

Àjàlá

Àdìó

Àmọ̀rí

Àmọ̀sá

Àmọ̀ó

Àmọ̀fẹ́

Àdìgún

Àdìsá

Àrẹ̀mú

Àrẹ̀ó

Àdèyí

### 4.3 Orúkọ-oríkì Obìnrin

Orúkọ-oríkì tí ó jẹ́ ti obìnrin náà pọ̀ lọ jàra ni. Lára àwọn oríkì obìnrin tí ó gbajúmọ̀ nìyí.

Àdùnní

Àyọ̀ká

Àkànkẹ́

Àmọ̀kẹ́

Àṣàkẹ́

Àṣàbí

Àsùnkẹ́

Àṣàní

Àyọ̀ní

Àbẹ̀ní

Àjọkẹ́

Àríkẹ́

Àjíkẹ́

Àtọ́kẹ́
Àgbékẹ́
Àbẹ̀ké
Àyìnkẹ́
Àníkẹ́
Àbẹ̀bí
Àbẹ̀ní
Àpínkẹ́
Àwẹ̀ró
Àlàkẹ́
Àjọró
Àlàrí
Àbẹ̀bí
Àbẹ̀mú
Àbẹ̀jẹ́
Àbẹ̀fẹ́
Àjín-ún
Èjìdé

**5.0 Ìsọnişókí**

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti ṣe àlàyé ní kíkún irú orúkọ tí oríkì jẹ́. A ti pààlà láàrin orúkọ-oríkì àti oríkì Yorùbá tí ó jẹ́ ewì. Bákan náà, a ti ṣe àpẹẹrẹ oríṣìíríṣìí orúkọ-oríkì tí ọkùnrin ń jẹ́ àti oríṣìíríṣìí orúkọ-oríkì tí obìnrin ń jẹ́ ní ilẹ̀ Yorùbá.

**6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe**

1. Ṣe àlàyé orúkọ-oríkì Yorùbá.
2. Sọ àwọn ìdí tí oríkì ṣe jẹ́ orúkọ ọ̀wọ̀ láàrin àwọn orúkọ tí a máa ń sọ ọmọ.
3. Sọ oríkì ọkùnrin mẹ́wàá àti ti obìnrin mẹ́wàá tí o mọ̀.

**7.0 Ìwé Ìtọ́kasí**

Adéoyè, C. L. (1979). *Àṣà àti Ìṣe Yorùba.* Ìbàdàn: Oxford University Press.

Dáramọ́lá O. & Jẹ́jẹ́ A. (1967). *Àṣà Àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn: Oníbọnòjé Press Limited.

Ládélé, T.A.A. *et al* (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ìbàdàn: Gavima Press.

**Ìpín Kejì Òrúkọ Àlàjẹ́**

**Àkòónú**

**1.0 Ìfáárà**

Ìsọ̀rí orúkọ kan pàtàki ni Orúkọ Àlàjẹ́ jẹ́ láàrin orúkọ Yorùbá. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé orúkọ àlàjẹ́ kì í ṣe èyí tí a pilẹ̀ sọ ọmọ lọ́jọ́ ìkọmọjáde, síbẹ̀ a fi máa ń pe ọmọ. Kódà, a ri orúkọ àlàjẹ́ mìíràn tí ó ti gbẹyẹ lọ́wọ́ orúkọ àbísọ gaan. Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ó ṣe àgbéyẹ̀wo orúkọ àlàjẹ́ ní kíkún.

**2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn**

Lẹ̀yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:

- sọ ìtumọ̀ orúkọ àlàjẹ́.
- sọ orísìírísìí orúkọ àlàjẹ́.
- ṣàlàyé orúkọ àlàjẹ́ kọ̀ọ̀kan.

**3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú**

1. Kín ni orúkọ àlàjẹ́?
2. Ṣàlàyé irú orúkọ tí à ń pè ní orúkọ àlàjẹ́.
3. Sọ orúkọ Yorùbá mẹ́jọ tí o mọ̀.
4. Sọ orúkọ àlàjẹ́ fún àwọn orúkọ mẹ́jẹ̀ẹ̀jọ tí o dá.
5. Ki oríkì mẹ́rin nínú àwọn orúkọ àlàjẹ́ yìí ṣókí.

**4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

**4.1 Kín ni Orúkọ Àlàjẹ́?**

Àlàjẹ́ jẹ́ orúkọ tí òbí kò fi sọ ọmọ ní ọjọ́ ìsọmọlórúkọ àmọ́ tí ọmọ ń jẹ́. Orúkọ àlàjẹ́ ni a tún ń pè ní àdàpè tàbí àpèjá. Gẹ́gẹ́ bí èrò Adéoyè (1982:42), "orúkọ àlàjẹ́ tàbí àdàpè kì í ṣe orúkọ tí òbí sọ ọmọ rẹ̀ lọ́jọ́ ìkómọjáde." Gbogbo orúkọ àwọn tí ó gbajúmọ̀ ni ilẹ̀ Yorùbá ni ó ní àlàjẹ́. Bí àpẹẹrẹ, 'Ọlọ́fà iná' ni àlàjẹ́ tàbí àpèlé Tìmì Àgbàlé, 'Agbógungbórò' ni ti

Ògèdèǹgbé, 'Agbòǹgbò Àkàlà' ni ti Líṣàbí, 'Olódògbokẹ̀ri lógun' ni ti Ògúnmọ́lá tí í ṣe Baṣòrun Ìbàdàn, abbl. Èyí fi hàn pé láti ara orúkọ tí a bá sọ ọmọ ni àlàjẹ́ rẹ̀ ti máa ń jẹ jáde.

Bí a bá sọ ọmọ ń orúkọ kan tí ó gbajúmọ̀, bóyá nítorí pé ẹni tí ó kọ́kọ́ jẹ́ orúkọ náà tàbí ẹnìkan tí ó jẹ́ ẹ rí jẹ́ alágbára, onínúure, olókìkí, jagunjagun, akíkanjú, olówó tàbí ọlọ́rọ̀; ojú àmúyẹ ẹni bẹ́ẹ̀ ni a ó fi máa wo ọmọdé tí a fún ní orúkọ yìí, tí a ó sì gbé gbogbo òkìkí ẹni náa fún ọmọ tí a sọ ní orúkọ yìí.

Ó yẹ kí á mọ̀ pé lára àwọn orúkọ àlàjẹ́ wọ̀nyí ní oríkì nínú. Oríkì orúkọ àlàjẹ́ mìíràn lè jẹ́ ṣókí, oríkì òmíràn sì lè gùn.

### 4.2 Orúkọ Àlàjẹ́ ti Ọkùnrin

| ***Orúkọ*** | ***Àlàjẹ́*** |
|---|---|
| Abíọ́dún | Ọba |
| Abísóyè | Olóde Òkúta |
| Adéyanjú | Ẹlẹ́kùú-ńlá |
| Adéníji | Àpáta |
| Adélékè | Baba Onísọjú |
| Adémọ́lá | Ọmọ Erin jogún ọlá |
| Adégbóyèga | Àkànbí Erin |
| Adétúnjí | Oníwàré |
| Adéyẹmọ | Elétìkó |
| Adéyẹmí | Alówólódù bí ìyèré |
| Adégbọlá | Ọ̀rẹ́ Ànàgó |
| Àdìgún | Olódòdó |
| Àjàó | Onímọ̀ta |
| Àbú | Olódodo |
| Àjàyí | Ògídí Olú |
| Ajíbádé | Eléètú |
| Ògúndípẹ̀ | Arápásọwú |
| Ògúndèyí | Aléràáwọ̀ṣun |

| | |
|---|---|
| Ọláwálé | Arẹ́kùújó |

### 4.3 Orúkọ Àlàjẹ́ ti Obìnrin

Ó yẹ kí á mọ̀ pé bí àwọn ìsọ̀rí orúkọ Yorùbá yòókù ṣe wà fún takọtabo náà ni orúkọ àlàjẹ́ wà fún tọkùnrin tobìnrin. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé orúkọ àlàjẹ́ tí ó jẹ́ ti ọkùnrin pọ̀, síbẹ̀ àwọn obìnrin náà ní tiwọn pẹ̀lú oríkì tí ó bá wọn lọ. Ṣé a kò gbàgbé pé orúkọ àlàjẹ́ ń ṣàfihàn olówó, ọlọ́rọ̀, alágbára, akíkanjú, onípò àti ọlọ́lá. Ó túmọ̀ sí pé a ní àwọn obìnrin náà tí ólàmìlaaka ní gbobo ọ̀nà bí i ti àwọn ọkùnrin náà nìyẹn.  Díẹ̀ lára àwọn orúkọ àlàjẹ́ obìnrin nìwọ̀nyí.

| ***Orúkọ*** | ***Àlàjẹ́*** |
|---|---|
| Adéòtí | Ọlọ́rùn-un-sẹ̀gi |
| Àlàbá | Ẹrú ìbejì |
| Àfọ̀n | Ọwọ́ aró |
| Ajítòní | Olóòka ẹ̀rẹ |
| Àyìnkẹ̀/Àǹkẹ́ | Ọmọ Ẹ̀ṣọ́ Ọ̀yọ́ |
| Ṣẹ̀gilọlá | Ẹlẹ́yinjú ẹgẹ́ |
| Mopélọ́lá | Aláwoòkẹ̀tẹ́ (Aláwo ìkẹ̀tẹ́) |
| Ẹfúnṣetán | Ìyálóde |
| Adébísí | Olóǹkún |
| Adépàtẹ | Ìjẹ̀ṣà ọmọ alọ́balọ́rọ̀ |
| Aasà | Oníbúadé |

### 4.4 Oríkì Àwọn Orúkọ Àlàjẹ́ Kọ̀ọ̀kan

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ tẹ́lẹ̀, àwọn orúkọ àlàjẹ́ Yorùbá a máa ní oríkì. Oríkì orúkọ àlàjẹ́ lè mọ ní ṣókí, ó sì lègùn. Ẹ jẹ́ kí a wo àpẹẹrẹ díẹ̀.

| **Orúkọ àlàjẹ́** | **Oríkì** |
|---|---|
| Ìgè | Àdùbí |

| | |
|---|---|
| Àbú | Olódodo |
| Abíọ́dún | Ọba |
| Adéníran | Sàbia |
| Adégbóyèga | Àkànbí Erin<br>Abinú funfun bí ẹmu<br>Abìsàlẹ̀ ikùn bí i tákàdá |
| Adégbọlá | Ọ̀rẹ́ Ànàgó |
| Adélékè | Baba Onísọjú |
| Adéyanjú | Ẹlẹ́kùú-ńlá<br>Ẹlẹ́kùú-ńlá, adáṣọ-má-lè-gbé-e<br>Ọ̀wọ́wọ̣́ńwọ́ tíí wọsọ lóde ọ̀lẹ<br>Ẹ̀kú, ọkọ Àjọró |
| Adéníji | Àpáta<br>Àpáta le olóko dáa sí<br>Ẹ̀bìtì olóògùn<br>Ọkùnrin bẹ̀ǹbẹ̀ńgúdù |
| Adéyẹmí | Alówólódù bí ìyèré<br>Ọba tó lówó bí i rẹ́rẹ<br>Ọba tó là là là<br>Bíi Dáràálà tí í gún owó nínú odó |
| Àjàyí | Ògídíolú<br>Oníkànga àjípọn |

| | |
|---|---|
| | Òbómi òṣùùrù wẹdà |
| | Ẹni tí Àjàyí gbè, gbè, gbè, |
| | Tí kò lè gbè tán |
| | Igúnnugún níí gbe olúwarẹ lórí ẹyin |
| | Ìgòǹgò níí gbe olúwarẹ̀ lákìtàn |
| Àlàbí | Adéẹ̀yọ̀ |
| | Àlàbí jà lẹ́wọ̀n |
| | Olúbíirọm abólúmọdi |
| | Àlàbí Adéẹ̀yọ̀ |
| Adéòtí | Ọlọ́rùn-un-sẹ̀gi |
| Àlàbá | Ẹrú ìbejì |
| Àfọ̀n | Ọwọ́ aró |
| | Àfọ̀ṣìkẹ́ ọwọ́ aró baba Ògúnlẹ́yẹ |
| Ajítòní | Olóòka ẹ̀rẹ |
| Àyìnkẹ̀/Àǹkẹ́ | Ọmọ Ẹ̀ṣọ́ Ọ̀yọ́ |
| Ṣẹ̀gilọlá | Ẹlẹ́yinjú ẹgẹ́ |
| Mopélọ́lá | Aláwoòkẹ̀tẹ́ (Aláwo ìkẹ̀tẹ́) |
| Ẹfúnṣetán | Ìyálóde |
| Adébísí | Olóǹkún |
| | Ìdîkán ọmọ Ògbojà |
| | Adébísí ajífẹran jẹun |
| | Bí ọmọ ọdẹ |
| | Abi ìgéran bí ìṣù ẹ̀lú |
| Adépàtẹ | Ìjẹ̀ṣà ọmọ alọ́balọ́rọ̀ |
| Aasà | Oníbúadé |
| | Oníbúadé Òkòtòlomù |
| | Apẹ́kọrọ yílùú ká |
| | Agbéyàwó má ṣàna |

Ọ̀rọ̀rọ̀ a rọ́mọ sítẹ̀ẹ́
Ó gbé ìmọ̀le mì tagbádá tagbádá
Ìmọ̀le ń ṣe káì káì!
Oníbúadé ńṣe máa kálọ
Akọ oṣù tíí lé láàrin òru

**5.0 Ìsọniṣókí**

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti ṣàlàyé irú ìsọ̀rí orúkọ tí orúkọ àlàjẹ́ jẹ́. A jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé láti ipasẹ̀ jíjẹ́ alágbára, onínúure, olókìkí, jagunjagun, akíkanjú, olówó tàbí ọlọ́rọ̀ ni orúkọ àlàjẹ́ ti sábà máa ń jẹyọ. Bí a ti ní onírúurú orúkọ àlàjẹ́ tí ó jẹ́ ti ọkùnrin náà ni onírúurú orúkọ àlàjẹ́ ti obìnrin náà wà. A ti mú ọ̀pọ̀lọpọ̀ àpẹẹrẹ wá nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí. Oríkì àwọn orúkọ àlàjẹ́ kọ̀ọ̀kan tí ó jẹ́ ti takọ tabo ni a fi kásẹ̀ ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí nílẹ̀.

**6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe**

1. Irú orúkọ wo ni à ń pè ní orúkọ àlàjẹ́?

2a. Dárúkọ orúkọ àlàjẹ́ mẹ́fà tí ó jẹ́ ti obìnrin.

b. Ki oríkì mẹ́rin nínú àwọn orúkọ àlàjẹ́ yìí ṣókí.

3a. Dárúkọ orúkọ àlàjẹ́ mẹ́fà tí ó jẹ́ ti ọkùnrin.

b. Ki oríkì mẹ́rin nínú àwọn orúkọ àlàjẹ́ yìí ṣókí.

**7.0 Ìwé Ìtọ́kasí**

Adéoyè, C. L. (1979). *Àṣà àti Ìṣe Yorùba.* Ìbàdàn: Oxford University Press.
Dáramọ́lá O. & Jẹ́jẹ́ A. (1967). *Àṣà Àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn: Oníbọnòjé Press Limited.
Ládélé, T.A.A. *et al* (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ìbàdàn: Gavima Press.

**Ìpín Kẹta** **Orúkọ Ìnagijẹ**

**Àkòónú**

**1.0 Ìfáárà**

Ìsọ̀rí kan pàtàki ni orúkọ ìnagijẹ́ jẹ́ láàrin àwọn orúkọ Yorùbá. Orúkọ ẹ̀fẹ̀ tàbí àpárá ni ìnagijẹ àmọ́ bí eré bí àwàdà ó lè di orúkọ. Bí àpẹẹrẹ, a gbọ́ pé ìnagijẹ ni orúkọ àwọn ẹbí Àjànàkú àti ẹbí Àlùkò ní ìlú Ilésà tí ó wá di orúkọ. Nínú orí ẹ̀kọ́ yìí, orúkọ ìnagijẹ ni a ó máa gbéyẹ̀wò ní kíkún.

**2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn**

Lẹ̀yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:

- ṣe àlàyé ohun tí orúkọ ìnagijẹ jẹ́.
- sọ àbùdá orúkọ ìnagijẹ.
- ṣe àpẹẹrẹ orúkọ ìnagijẹ.

**3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú**

1. Ṣe àlàyé ohun tí orúkọ ìnagijẹ jẹ́.
2. Kín ni àwọn àbùdá orúkọ ìnagijẹ?
3. Ṣọ àpẹẹrẹ orúkọ ìnagijẹ mẹ́fà tí o mọ̀.

**4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

**4.1 Kín ni Orúkọ Ìnagijẹ?**

Irúfẹ́ orúkọ àlàjẹ́ mìíràn ni ìnagijẹ. Ìnagijẹ ni orúkọ ẹ̀fẹ̀, orúkọ àwàdà tàbí àpèlé tí àwọn ẹgbẹ́, ọ̀gbà tàbí irọ̀ ẹni fi máa ń sọni. Kódà, ènìyàn lè mọ̀-ọ́n-mọ̀ sọ ara rẹ ní ìnagijẹ tí ó bá fẹ́ tí àwọn ènìyàn yóò sì máa pè é bẹ́ẹ̀. Gẹ́gẹ́ bí gbogbo orúkọ yòókù ṣe máa ń bá ìwà àti ìṣe tan, bẹ́ẹ̀ náà ni orúkọ ìnagijẹ náà máa ń ti ara ìwà tàbí ohun tí ẹnìkan kúndùn jáde. A ti rí àwọn tí ìnagijẹ mọ́ lára tímọ́tímọ́ tí ó sì ṣe bẹ́ẹ̀ di orúkọ wọn.

## 4.2 Àbùdá Orúkọ Ìnagijẹ

Ìgbà tí a wà ní ilé-ẹ̀kọ́ gíga, ọ̀kan lára àwọn agbábọ́ọ̀lù wa ń jẹ́ Kúnle. Báyìí ni ó pe ara rẹ̀ ní 'Àwésù'. Ṣé a kò gbàgbé pé Kúnlé Àwésù jẹ́ ọ̀kan lára àwọn agbábọ́ọ̀lù fún ikọ̀ IICC Shooting Stars ní Ìbàdàn ni ìgbà pípẹ́ díẹ̀ sẹ́yìn. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé Kúnlé Ìgè ni akẹ́kọ̀ọ́ yìí ń jẹ́, ó tìkalára rẹ̀ sọ ara rẹ̀ di Kúnlé Àwésù nítorí pé ó fẹ́ jọ gbajúgbajà agbábọ́ọ̀lù yìí. Fífí ìwúrí bá àwọn àgbábọ́ọ̀lù jẹ́ orúkọ tilẹ̀ wọ́pọ̀ gan-an ni. Ọ̀pọ̀ àwọn èe àti ọ̀dọ́ ni ó sọ ara wọn ní Ọdẹ́gbàmí, Kánu, Okocha, Yẹ̀kínì, Màràdónà, Bẹ̀bẹ́tò, Rònádò, Mẹ́sì, abbl. Bí àwọn ènìyàn ti ń fi àwọn tí ó gbajúmọ̀ fún iṣẹ́ rere yangàn nípa bíbá wọn jẹ́ orúkọ náà ni àwọn ènìyàn lè yan orúkọ aṣebi ẹ̀dá ní ìnagijẹ. Ní àìpẹ́ yìí ni a gbọ́ ti àwọn ìpẹ́ẹ̀rẹ̀ olè meta tí wọ́n sọ ara wọn ní Oyèénúsì, Aníní àti Òsunbọ̀. Àwọn olè adàlúrú paraku ni Oyèénúsì, Aníní àti Òsunbọ̀ ní ìgbà tiwọn.

Ìnagijẹ yàtọ̀ sí orúkọ àlàjẹ́ tí a sọ̀rọ̀ bá ní abala àkọ́kọ́ ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí nítorí pé kò ti ara orúkọ àbísọ jẹyọ, ọjọ́ ìkómọjáde sì kọ́ ni a máa ń sọni ní ìnagijẹ. Ìnagijẹ kò ní ọjọ́ orí tàbí ìgbà. Ènìyàn lè ní ìnagijẹ ní ìgbà èwe tàbí àgbà àmọ́ ìgbà ọ̀dọ́ bí a bá wà ní ilé ẹ̀kọ́ tàbí ẹnu ẹ̀kọ́ṣẹ́ ni sisọni ní ìnagijẹ máa ń wọ́pọ̀. Ìnagijẹ tí a fi ń ṣe àyẹ́sí ẹni wà, pẹ̀lú ìwúrí sì ni a fi máa ń jẹ́ irú orúkọ ìnagijẹ bẹ́ẹ̀. Àmọ́ ìnagijẹ mìíràn wà tí ó tàbùkù ẹni tí ó sì máa n bọ́ sí àpò ìbínú ẹni tí a bá ń pè bẹ́ẹ̀. Irú ẹni bẹ́ẹ̀ lè fi ìbínú àti ìjà kọ orúkọ náà kí ó sì gbà á lẹ́nu àwọn ẹgbẹ́ rẹ̀ tí ó ń pè é bẹ́ẹ̀.

## 4.3 Àpẹẹrẹ Orúkọ Ìnagijẹ

Gẹ́gẹ̀ bí àwọn ìsọ̀rí orúkọ Yorùbá yòókù, ọkùnrin máa ń ní ìnagijẹ, obìnrin náà sì máa ń ní ìnagijẹ àmọ́ ìnagijẹ wọ́pọ̀ láàrin àwọn ọkùnrin ju obìnrin lọ. Àpẹẹrẹ orúkọ ìnagijẹ

| ***Ọkùnrin*** | ***Obìnrin*** |
|---|---|
| Bàbálájé | Ayílukọ |
| Bàbá ìṣòwò | Ìdí ìlẹ̀kẹ̀ |
| Béńtílé | Wẹ̀-ẹ́-lẹ́rìn-ín |
| Àwésù | Ẹlẹ́rìín-ẹ̀yẹ |

Eyín afẹ̀

Àjànàkú

Ejò nígboro

Bàlóò (Balógun/Balógun lẹ́yìn obìnrin)

Ayọ̀ (Ayọ́mẹ́yẹ)

**5.0 Ìsọnișókí**

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti ṣe àlàyé ohun tí orúkọ ìnagijẹ jẹ́. A jẹ́ kí ó di mímọ̀ pé orúkọ ìnagijẹ kì í ṣe èyí tí ìdílé péjọ pọ̀ sọ ọmọ ní ọjọ ìsọmọlórúkọ tàbí ìkómọjáde. A sọ àwọn àbùdá tí a mọ̀ mọ orúkọ ìnagijẹ. Bákan náà ni a sì ṣe àpẹẹrẹ orúkọ ìnagijẹ díẹ̀.

**6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe**

1. Kín ni à ń pè ní orúkọ ìnagijẹ?
2. Sọ nǹkan mẹ́rin tí o mọ̀ nípa orúkọ ìnagijẹ.
3. Dárúkọ orúkọ ìnagijẹ ọkùnrin mẹ́fà.
4. Dárúkọ orúkọ ìnagijẹ obìnrin mẹ́fà.

**7.0 Ìwé Ìtọ́kasí**

Adéoyè, C. L. (1979). *Àṣà àti Ìṣe Yorùba.* Ìbàdàn: Oxford University Press.

Dáramọ́lá O. & Jẹ́jẹ́ A. (1967). *Àṣà Àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn: Oníbọnòjé Press Limited.

Ládélé, T.A.A. *et al* (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ìbàdàn: Gavima Press.

**Ìpín Kẹrin: Ìpèníjà fún Orúkọ Yorùbá**

**Àkòónú**

**1.0 Ìfáárà**

Ilé ayé kún fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìpèníjà àti ìdojúkọ. Ohun gbogbo ni ìdojúkọ wà fún. Pàápàá ní ayé ọ̀làjú tí a wà yìí, ọ̀pọ̀ ìpèníjà ni ó ń ṣẹ́ yọ. Ìkọlura àṣà, ìkọlura ẹ̀sìn, ọ̀làjú, ètò okòwò àti ọrọ̀ ajé, ìmọ̀ ẹ̀rọ, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ ń ṣe okùnfà ìpèníjà fún àwùjọ.

Ìpèníjà ń dé bá àṣà káàkiri àgbáyé, èyí náà ni ó sì dífá fún ìdojúkọ tí orúkọ Yorùbá ń rí lóde òní. Kò sí àníàní pé àṣà òkèèrè, ẹ̀sìn òkèèrè, ọ̀làjú àti àṣà ìgbàlódé ń ṣe ọ̀pọ̀ àkóbá fún orúkọ Yorùbá. Ìdojúkọ wọ̀nyí ni a ó máa gbé yẹ̀wò nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí.

**2.0 Èròǹgbà àti Àfojúsùn**

Lẹ̀yìn ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, akẹ́kọ̀ọ́ yóò lè:

- ṣe àlàyé ohun tí a pè ní Ìwọ́ká Ìran Yorùbá.
- ṣe àlàyé ìpèníjà fún orúkọ Yorùbá nípasẹ̀ ẹ̀sìn.
- ṣe àlàyé ìpèníjà fún orúkọ Yorùbá nípasẹ̀ èdè.
- ṣe àlàyé ìpèníjà fún orúkọ Yorùbá nípasẹ̀ àkọtọ́.

**3.0 Ìbéèrè Ìṣaájú**

1. Ṣe àlàyé Ìwọ́ká Ìran Yorùbá.
2. Báwo ni orúkọ Yorùbá ṣe ní ìpèníjà nípasẹ̀ ẹ̀sìn?
3. Ìpèníjà wo ni orúkọ Yorùbá ní nípasẹ̀ èdè?
4. Ṣe àlàyé ìpèníjà tí ó dé bá orúkọ Yorùbá nípasẹ̀ àkọtọ́.

**4.0 Ìdánilẹ́kọ̀ọ́**

Oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni ìpèníjà fi ń dé bá orúkọ Yorùbá lóde òní. Nínú ẹ̀kọ́ yìí, a ó ṣe àlàyé díẹ̀ nínú rẹ̀. Àwọn náà ni Ìwọ́ká ìran Yorùbá, Ìpèníjà nípasẹ̀ Ẹ̀sìn, Ìpèníjà nípasẹ̀ èdè, àti Ìpèníjà nípasẹ̀ Àkọtọ́.

## 4.1 Ìwọ́ká Ìran Yorùbá

Káàkiri àgbáyé, ìran ọmọnìyàn kò dúró sí ojúkan mọ́. Gbogbo ọmọ orílẹ̀ èdè àgbáyé ni ó ń fi ìlú abínibí wọn sílẹ̀ lọ sí ìlú àti ilẹ̀ mìíràn nítorí okòwò àti ọrọ̀ ajé. Ṣe ni ọmọ adáríhurun ń wọ́ káàkiri láti wá ìmọ̀, ẹ̀kọ́, iṣẹ́, ìtẹ̀síwájú, ìfọ̀kànbalẹ̀ àti àlàáfíà. Gbogbo ẹ̀yà ni ó gùn lé ìwọ́ká, èyí kò sì yọ ìran Yorùbá pàápàá sílẹ̀. Ìwọ́ká túmọ̀ sí títàn káàkiri àgbáyé. Ìwọ́ká ni fífi ìlú abínibí ẹni sílẹ̀ lọ ṣe àtìpó ní ilẹ̀ mìíràn. Raji (2005) siṣẹ́ lórí ìfọ́nká àwọn ọmọ Odùduwà sí orílẹ̀ àgbáyé. Oríṣìí ìfọ́nká mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ ni ó tọ́ka sí. Àwọn ni Ìfọ́nká Ìpilẹ̀ṣẹ̀, Ìfọ́nká Alákọni, àti Ìfọ́nká Ológun àti ọ̀tẹ̀.

Láti ipasẹ̀ ìfọ́nká ni Odùduwà ti fi ìhà ìlà oòrùn sílẹ̀ wá tẹ̀dó sí Ilé-ifẹ̀. Níṣojú Odùduwà ni Ọ̀kànbí tí í ṣe ọmọ kanṣoṣo tí ó bí, àti àwọn ọmọ méjèèje tí Ọ̀kànbí fúnraarẹ̀ bí ṣe fọ́nká láti tẹ oríṣìíríṣìí ìlú dó káàkiri ilẹ̀ Yorùbá. Gẹ́gẹ́ bí èrò Rájí (2005), láti ipasẹ̀ ìfọ́nká ni ilẹ̀ Yorùbá ṣe fẹ̀ débi tí ó fẹ̀ dé yìí. Èyí ni Ìfọ́nká ìpilẹ̀ṣẹ̀.

Àwọn akọni, pàápàá jagunjagun, kì í fẹ́ wà lábẹ́ àṣẹ ẹlòmíràn lọ títí. Ìpòǹgbẹ fún jíjẹ́ olórí àti síṣe àkóso a máa mú kí àwọn akọni àti alágbára kó àwọn ọmọ abẹ́ wọn kúrò láti lọ tẹ ìlú dó fún ara wọn kí wọ́n sì di baálẹ̀ níbẹ̀. Ìfọ́nká Alákọni ni èyí. Èyí náà sì ṣe okùnfà fífẹjú tí ilẹ̀ Yorùbá fẹjú lónìí. Ipasẹ̀ èyí ni Lágelú fi tẹ ìlú Ẹ̀bá Ọ̀dàn dó, tí Ṣọ̀ún Ogunlọlá fi tẹ Ògbómọ̀ṣọ́ dó, tí Tèlú pẹ̀lú fi kúrò ní Ilé-ifẹ̀ lọ tẹ ìlú Ìwó dó. Ìfọ́nká Ológun pẹ̀lú mú ìtànkálẹ̀ bá àwọn ọmọ kóoótù-oòjíire. Dúkùú, ìjà, ọ̀tẹ̀, rògbòdìyàn àti ogun fa ìdìde àti ìṣubu ọ̀pọ̀ ìjọba ńlá bí i Ọ̀yọ́, Ìjẹ̀bú, Èkìtì, Ìjẹ̀ṣà, Ìgbómìnà, Oǹdó, Kétu, Ṣábẹ̀ẹ́, Ẹ̀gbá, Ẹ̀gbádò, abbl. Ìjẹgàba àwọn òyìnbó àti òwò ẹrú ti sọ àwọn ọmọ Yorùbá di onílé àti onílẹ̀ ní Cuba, Brazil, ilẹ̀ Trinidad àti Tobago, West Indies, Sierra Leone, Liberia, abbl.

Ọ̀làju, ìgbàlóde àti ayé-lu-jára ni ó ń ṣokùnfà ìwọ́ká àti ìṣànká àwọn ọmọ Yorùbá jùlọ lóde òní. Àwọn ọmọ Yorùbá ti pọ̀ rẹpẹtẹ ní ilẹ̀ Gẹ̀ẹ́sì, Amẹ́ríkà, Canada, àwọn orílẹ̀ èdè ní Yúróòpù, Saudi Arabia, káàkiri ilẹ̀ Áfíríkà, abbl. Ó fẹ́rẹ̀ẹ́ má sí ibi tí ọmọ Yorùbá kò ti máa ṣe àtìpó lórílẹ̀ àgbáyé, kódà, ọ̀pọ̀ kò lè mọ ọ̀nà ilé mọ́. Ẹ̀wẹ̀, látàrí ìdojúkọ ètò ààbò, ọrọ̀ ajé àti àìríṣẹ́ṣe, ọ̀pọ̀lọpọ̀ ni ó ń fi ojoojúmọ́ sá jáde láìbojúwẹ̀yìn mọ́. Ìwọ́ká yìí ń ní ipa tí ó ga lórí èdè àti àṣà Yorùbá, pàápàá orúkọ jíjẹ́. Ọ̀pọ̀ ọmọ tí a bí sí òkèèrè ni wọn kò sọ ní orúkọ Yorùbá rárá. Ọ̀pọ̀ ni ó sì jẹ́ pé àmúlùmálà orúkọ ni wọ́n ń jẹ́. Kódà a rí àwọn òbí àti

àgbàlagbà tí ó ń pa orúkọ dà nílùú onílùú, dájú dájú, à kò lè retí pé kí irú wọn sọ ọmọ tí wọ́n bá bí ní orúkọ Yorùbá. Èyí jẹ́ ara ìpèníjà tí ó dé bá orúkọ Yorùbá láti ipasẹ̀ ìwọ̀ká.

## 4.2 Ìpèníjà nípasẹ̀ Ẹ̀sìn

Ó fẹ́rẹ̀ẹ́ jẹ́ pé ẹ̀sìn ni ó ṣe àkóbá jù fún orúkọ Yorùbá ní pàtó, àti èdè òun àṣà Yorùbá ní àpapọ̀. Ẹ̀sìn àtọ̀húnrìnwá méjèèjì; ẹ̀sìn ọmọlẹ́yìn Jésù àti ẹ̀sìn Mùsùlùmí ṣe àkóbá púpọ̀ fún orúkọ jíjẹ́. Láwùjọ wa lónìí, bí a kò bá gbọ́ Sàámú, Jọ̀ọ́nú, Jákọ́bù, Dáfídì, Mósè, Pétérù, Dáníẹ̀lì, Rèbékà, Lìdíà, Màríà, Réṣẹ́ẹ̀lì, Rúùtù; Mòhámẹ́ẹ̀dì, Hàmẹ́ẹ̀dì, Àkíìmù, Ṣàráfà, Ràsákì, Lúkúmọ́nù, Àsíìsì, Rékìyá, Áìsá, Méríàmù, Báràká, Ṣẹ̀kínátù, abbl ni a ó máa gbọ́. Kódà, a ti bá a débi pé orúkọ ẹ̀sìn pọ́nńbélé ni àwọn ọmọ ń jẹ́ ní ilé ẹ̀kọ́ báyìí. Moses Joseph, Deborah Samson, Raphael Daniel, Lydia Johnson, Ahmed Rasaq, Rekiya AbduSalam, Sekinat Abubakar, abbl ni àwọn ọmọ wa ń jẹ́. Àwọn ẹlẹ́sìn méjèèjì ni ó ń ṣògo nínú jíjẹ́ orúkọ ẹ̀sìn wọn láìkọbiara sí ìpalára àti àkóbá tí ó ń ṣe fún èdè àti àṣà Yorùbá.

## 4.3 Ìpèníjà nípasẹ̀ Àkọtọ́

Àṣà burúkú tí àwọn ọ̀dọ́ kó wọ àwùjọ wa ní ọdún díẹ̀ sẹ́yìn tún jẹ́ orísun àkóbá gidi fún orúkọ Yorùbá. Àṣà yìí ní ṣe pẹ̀lú àkọtọ́ Yorùbá. Níṣe ni àwọn ọ̀dọ́ wọ̀nyí bẹ̀rẹ̀ sí fi èdè Gẹ̀ẹ́sì kọ orúkọ Yorùbá. Bí wọ́n bá ṣe àmúlùmálà yìí tán, orúkọ ọ̀hún kò ní jọ ti Yorùbá rárá. Ẹ jẹ́ kí a kíyèsí àwọn àpẹẹrẹ yìí:

| **Àkọtọ́ Yorùbá** | **Àkọtọ́ Àmúlùmálà** |
|---|---|
| Olúṣọlá | Horlushorlar |
| Adébọ́lá | Hardeborla |
| Jọmílójú | Jormilorjuh |
| Adéníyì | Hardeniyih |
| Adéníkẹ̀ẹ́ | Hardenikhe |
| Olúkẹ́mi | Horlurkemy |
| Rẹ̀mí | Rehmy |
| Ṣade | Shardey |
| Adétúnjí | Hardeytunjy |

| | |
|---|---|
| Tómilọ́lá | Tormylorlar |
| Fúnmiláyọ̀ | Funmylaryor |
| Sùnńbọ̀ | Sunnybor |
| Ọmọlọlá | Hormorlorlar |
| Ọmọlará | Hormorlahrar |

Àkóbá burúkú gbáà ni èyí jẹ́ fún ogún ribiribi tí àwọn baba ńlá ìran Yorùbá fi sílẹ̀ fún wa nípasẹ̀ orúkọ.

**5.0 Ìsọnişókí**

Nínú ìdánilẹ́kọ̀ọ́ yìí, a ti ṣe àlàyé púpọ̀ lórí àwọn ohun tí ó ń ṣe okùnfà ìpèníjà fún orúkọ Yorùbá. Ìwọ́ká ìran Yorùbá, ìpèníjà nípasẹ̀ Ẹ̀sìn àti ìpèníjà nípasẹ̀ Àkọtọ́ ni àwọn kókó tí a tọ́kasí.

**6.0 Iṣẹ́ Ṣíṣe**

1. Ṣe àlàyé Ìwọ́ká Ìran Yorùbá.
2. Dárúkọ oríṣìí Ìfónká tí Raji (2005) tọ́kasí kiM o sì ṣe àlàyé ṣókí lórí ọ̀kọ̀ọ̀kan.
3. Báwo ni orúkọ Yorùbá ṣe ní ìpèníjà nípasẹ̀ ẹ̀sìn?
4. Ìpèníjà wo ni orúkọ Yorùbá ní nípasẹ̀ èdè?

**7.0 Ìwé Ìtọ́kasí**

Adéoyè, C. L. (1979). *Àṣà àti Ìṣe Yorùba.* Ìbàdàn: Oxford University Press.
Dáramọ́lá O. & Jẹ́jẹ́ A. (1967). *Àṣà Àti Òrìṣà Ilẹ̀ Yorùbá.* Ìbàdàn: Oníbọnòjé Press Limited.
Ládélé, T.A.A. *et al* (2006). *Àkójọpọ̀ Ìwádìí Ìjìnlẹ̀ Àṣà Yorùbá.* Ìbàdàn: Gavima Press.
Raji, S. M. (2005). Igbó Ẹwẹ. Ibadan: Masterprint Publishers.